# Òùngbẹ

Tucson, Arizona USA

Ọjọ Karundogun, Oṣu Kẹsan, 1965

1 Ẹ ku irọlẹ, ẹyin ọrẹ. Anfaani ni o jẹ lati wa nibi lalẹ yii. Igba keji niyi ti emi yoo wa ni Grantway Assembly yii pẹlu Arakunrin ọwọn Mack, ati gbogbo awọn osiṣẹ to dara wọnyi, pẹlu awọn Kristẹni to dapọ mọ wọn lati awọn Ijọ miran. Arakunrin Lee Vayle ati arakunrin kan ti mo ṣẹṣẹ pade nibi yii tii ṣe ọrẹ Arakunrin F.F. Bosworth, ti ko tilẹ mọ wipe Arakunrin Bosworth ti lọ wa pẹlu Oluwa. Mo wipe, “Mo nimọlara pe, mo pade Elisha to bu omi sọwọ Elija. O ti lọ soke okun, ko si mọ pe Arakunrin Bosworth ti lọ sọdọ Oluwa ni ẹni Ọgọrin ati mẹrin ọdun.

2 Bayi, mo fẹ ki awọn ara ti wọn ngbọ wa lori ẹrọ ibanisọrọ lalẹ yii kaakiri orilẹ-ede yii, lati Carlifornia titi de New York, Texas, ati gbogbo orilẹ-ede lati Maine de California. Nitori naa, a ni eto kan ti a fi nlo ẹrọ ibanisọrọ wọnyi, ti o si ti jẹ ibukun.

A si ni oye nipasẹ ọrẹ wa tootọ, Arakunrin Pearry Green pe ohun kan wa ti wọn lee fi sori ẹrọ mohun-maworan. Kii ṣe wipe yoo wa lori ẹrọ ibanisọrọ wọn nikan, ṣugbọn yoo han ninu apoti mohun-maworan pẹlu. Wọn si nwo bayi.

3 Arabinrin Mack, inu mi dun lati ri ọ ni alaafia ti o si joko nibi duuru lalẹ yii. Ọpọ awọn ọrẹ mi, ti o wa lati Sierra Vista ni mo si ri, ati Arakunrin Borders, tabi Arakunrin Roberson ni mo fẹ sọ lati Indiana. Mo fẹ sọ fun awọn ara to wa ni ile Isin ni Jeffersonville lalẹ yii; o dabi ẹni pe ilaji wọn lo wa nibi.

Ati si ọrẹ mi; Arakunrin Kuntz, ti o pe mi nipa alaisan yẹn, mo ngbadura fun un, Arakunrin Kuntz. Iwọ sa ti ni igbagbọ. Ma mikan. Gbogbo rẹ yo dara.

Ati ni Texas - arakunrin Blair, bi iwọ ba nfeti-silẹ lalẹ yii, arakunrin mi, saa ranti eleyi: Pe Ọlọrun ti o yọ ọ nigba akọkọ, lee tun yọ ọ nigba keji yii. A si ngbagbọ pe Ọlọrun yoo ṣe eleyi fun ọ. Iwọ ma ṣe gba irọ ti eṣu nipa ohunkohun. Iwọ sa ti ranti wipe, Ọlọrun ni Ọlọrun. Oun si jẹ ọkan naa sibẹ, lana, loni ati titi lae. Awa si nifẹ Rẹ, a si gba A gbọ, a si ngbadura fun ọ.

Gbogbo awọn ọrẹ wa ni California, ati si Arakunrin Mercier ati awọn to wa ni Arizona nihin, ni ibi gbogbo, ni Phoenix ati Arakunrin Williams - ti ẹ si ngbọ wa lalẹ yii, kaakiri. Dajudaju, a mọ riri yin. Ati ni Georgia, dajudaju, a dupẹ fun Olukuluku yin. Ki Oluwa bukun yin.

4 Mo ni imọlara pe a ki mi kaabọ gidi nibi lalẹ yii si ijọ to dara ti Assembly of God nibi ni Grantway, ati pẹlu Arakunrin Mack, ọrẹ mi gidi. Ọlọrun ti bukun Arakunrin Mack. Mo ranti ni igba kan ni Canada, mo ngun ẹṣin lọ loju opo ẹsin kan ninu igbo. Ẹmi Mimọ si bami sọrọ pe ki nsọkalẹ, ki nsi gbadura fun Arakunrin Mack. Ni akoko naa, ara rẹ ko da rara, o wa ni ẹsẹ kan aye, ẹsẹ kan ọrun. Oluwa si wo o san. Mo dupẹ fun iyẹn, ati lati wa papọ nibi lalẹ yii lati sin Oluwa ninu otitọ daradara yii.

Ọkunrin kan ti o joko lẹyin mi lori pẹpẹ wipe, “O dabi ẹnipe, iwọ ko mọ mi. Nigbakan, iwọ gbe mi nibiti mo ti nrin, ti mo si nwa ọkọ ti yoo gbe mi lọfẹ.” Mo gbe e nibi kan ni adugbo Boston tabi Detroit ti o nfẹ iranlọwọ.

Mo dahun wipe, “Emi ma a nṣe iranlọwọ, bi o ba ṣeeṣe, fun awọn to nilo iranlọwọ.” Nitori naa, lalẹ yii, gbogbo wa ni a nilo iranlọwọ. A gbadura pe ni alẹ yii, Ọlọrun yoo nawọ Rẹ Jade si wa fun Iranlọwọ, Ibukun; oore-ọfẹ ati aanu Rẹ.

5 Emi a maa sọrọ pẹ pupọ. Ṣugbọn emi yoo gbiyanju lati ma ṣe bẹẹ lalẹ yii, Nitoripe awọn ara ni Ohio ti pe - Iya aafin Dauch ati awọn to wa nibẹ, Arakunrin Mckinney ati Arakunrin Brown ati gbogbo awọn to ngbọ iwaasu yii nipa ẹrọ ibanisọrọ ni Ohio. A ki i yin pẹlu. Ilẹ ti ṣu ni New York, mo si ro pe, nkan bi agogo mọkanla tabi Mejila oru ni bayi. Awọn ijọ si wa lati parapọ fun lati gbọ Ọrọ yii. A dupẹ fun awọn ọrẹ gidi bẹẹ kaakiri.

6 Bayi, ki a to ka ninu Ọrọ naa, ẹ jẹ ki a ba ẹniti o kọ ọ sọrọ ni kukuru, bi a ṣe tẹri wa ba.

Baba wa Ọrun, inu wa dun pupọ fun anfaani ti a ni lati wa laaye ati lati pe jọpọ pẹlu awọn eniyan Rẹ ti a gbagbọ pe a o jọ gbe titi lae. A ti ni Iye ainipẹkun nisisiyi, nitoripe Iwọ fi ọmọ bibi Rẹ kanṣoṣo silẹ pe ki ẹnikẹni ti o ba gbagbọ ninu Rẹ, ma ba ṣegbe, ṣugbọn ki o le ni Iye ainipẹkun. Ninu atipo Rẹ laye yii, o kọ wa wipe, “Ẹniti o ba gbọ Ọrọ Mi, ti o si gba Ẹniti O ran Mi gbọ ni Iye ainipẹkun, oun ki yoo si wa si idajọ, ṣugbọn o ti rekọja Iku si Iye, nitoriti awa gba ọmọ bibi kanṣoṣo Ọlọrun gbọ. Awa dupẹ pupọ fun Olugbala nla yii. A si gbadura lalẹ yii pe ki Iwalaaye nla Rẹ bukun wa papọ nibi yii bi a o ti ka Ọrọ Rẹ, ti a o si sọrọ nipa rẹ. Jẹ ki Ẹmi Mimọ mu Ọrọ naa wọ inu aladori ẹnikọọkan ti o gbọ ọ jakejado orilẹ-ede yii, Oluwa, ni gbogbo ibiti a pe jọ si.

Bukun awọn Iranṣẹ Rẹ ti o ku, ti wọn wa ninu aga iwaasu. A gbadura Baba, pe ki o bukun Ipejọpọ

Grantway Assembly, Oluṣọ-aguntan rẹ, iyawo rẹ, awọn ọmọ rẹ. Baba, ni apapọ, jẹ ki a siṣẹ fun Ijọba Ọlọrun nigbati a ni imọlẹ to lati riran. Nitori wakati nbọ wa, nigbati ẹnikẹni ko ni le siṣẹ. Baba, nigbati a ni anfaani yii, jẹ ki a ra igba pada, Oluwa. Ṣe eyi fun wa. Mu awọn alaisan larada ni gbogbo orilẹ-ede naa.

Jẹ ki a ni imọlara Iwalaaye Ọlọrun kaakiri gbogbo orilẹ-ede lalẹ yii.

7 A mọ wipe idajọ nkọlu aye. Awọn ila ìṣẹ́lẹ̀ ńlá ti wà, orilẹ-ede sin nmi, ìṣẹ́lẹ̀ kaakiri - awọn nkan isẹmbaye ti a ti gbọ lati ọjọ pipẹ, awọn idajọ ninu Bibeli - a si rii ti wọn nṣẹlẹ loni lẹẹkansi. Isọtẹlẹ to wipe "Gẹgẹ bi o ti ri ni ọjọ Noah, bẹẹ ni yoo ri ni ọjọ bibọ Ọmọ eniyan naa. Bi o si ti ri ni ọjọ Lọti, bẹẹ ni yoo ri ni ọjọ bibọ Ọmọ eniyan naa" A si ri i ti o ńṣẹlẹ̀ nisisiyi. Ọkan awọn eniyan nfo; akoko idaamu, irukerudo laarin awọn orilẹ-ede. Ọlọrun, awa mọ pe a ti wa ni opin aye. Ran wa lọwọ, Oluwa, lati mu iṣẹ iranṣẹ Ọrọ Rẹ lọ si ibi gbogbo, tọ gbogbo awọn ọmọ ti O ti yantẹlẹ si Iye. Ṣe bẹẹ Oluwa. A beere ni Orukọ Jesu. Amin.

Ki Oluwa bukun kika Ọrọ Rẹ nisisiyi.

8 Ọpọ yin ni o nifẹ lati ma a ka Bibeli pẹlu Oniwaasu bi o ti n ka a. Mo fẹ ka ẹsẹ diẹ ninu Orin Dafidi 42 fun Ọrọ ipilẹ. Mo si ni awọn Iwe Mimọ kan ti mo kọ silẹ, ti mo fẹ tọka si bi a ti ntẹsiwaju fun iṣẹju diẹ, lati sọrọ lori akori yii. Dafidi ni o kọ Saamu. Nigbati ẹ n ṣi i lọwọ, mo le sọ eleyi. Ọpọ eniyan wipe, "Njẹ a misi awọn Orin Dafidi bi?" Dajudaju, a mi si wọn. Ohunkohun ti o wa ninu Bibeli yi, a mi si i. Yala o jẹ itan, tabi orin - ohunkohun ti o jẹ - a mi si i. Jesu wipe, "Se ẹyin ko ti ka ohun ti Dafidi sọ ninu Saamu?" Mo si gbagbọ pe Saamu jẹ awọn orin. Bi a ba si misi awọn orin mimọ lati ọdọ Ọlọrun, mo si gba bẹẹ, wọn si tun sọtẹlẹ, mo nireti pe emi yo wa nibẹ lọjọ naa ti a o mu orin yii ṣẹ:

Ipade nla kan yoo wa lofurufu

Lọjọ didan kan laipẹ

Mo fẹ ri ọ, ka pade nibẹ

Nile naa l'ofurufu

Orin naa tẹ o gbọ

Ti eti kan ko gbọ ri

Yoo logo, mo sọ fun ọ!

Ọmọ Ọlọrun ni yoo ṣaaju. Nipade lofurufu.

Ah. Mo fẹ wa nibẹ nigba naa.

9 Bayi, Saamu 42

Bi agbọnrin ti ma a nmi hẹlẹ si ipado omi, Ọlọrun, bẹẹ ni ọkan mi nmi hẹlẹ si ọ.

Oungbẹ Ọlọrun ngbẹ ọkan mi, ti Ọlọrun alaaye: nigbawo ni emi o wa, ti emi o si yọju niwaju Ọlọrun.

Omije mi ni ounjẹ mi ni ọsan ati ni oru, nigbati wọn nwi fun mi nigba gbogbo pe, Ọlọrun rẹ da?

Mo ro wipe Dafidi wa ninu ipọnju ni akoko ti o kọ Psaamu yii. O si maa ngba ipọnju lati mu ohun ti o dara julọ ninu ẹnikan jade. Nigba naa ni Ọlọrun maa nba eniyan sọrọ. Nigbati a ba gbaawẹ lọpọ igba, lati mu ara wa si ipo ti o tọ, lati mu ara wa kuro lọna. Mo ro pe, nigbati Dafidi de ipo idaamu wọnyi, nigba naa ni o bẹrẹ si ṣe aṣaro nipa Oluwa, o ronu nipa nkan.

Ni ọpọ igba, Ọlọrun ma a nmu wa bọ si ibi hiha, nibiti a nilati wo oke. Nigba miran, a nilati de ori akete aisan nile iwosan tabi nibi kan, ki a lee wo oke lati ri ibiti awọn Ibukun Ọlọrun ti nwa.

10 Ọrọ ti mo fẹ sọrọ le lori lalẹ yii lati inu Bibeli ni a ri ni ẹsẹ keji "Oungbẹ" Mo si wo inu iwe ti a fi ntumọ ede gẹẹsi. Nigbati mo nwo Ọrọ yii, mo nro nipa iwaasu kan ti mo ṣe nigba kan lori. "Oungbẹ si Iye" Mo mu iwaasu naa lati inu Psaamu pẹlu, nibiti Dafidi ti wipe, "Awọn Ilana Rẹ ṣe iyebiye simi ju Iye lọ" Nigbana, mo nyẹ ọrọ yẹn wo tii ṣe "Oungbẹ." Nitori naa, mo wo o ninu iwe ti a fi ṣe itumọ awọn ọrọ, lati ri ohun ti o tumọ si. Ohun ti Webster si sọ niyii. O jẹ ifẹ ọkan kan ti o ndun ni de inu; nigbati iwọ ba nsafẹri ohun kan to bẹẹ ti o fa irora ọkan fun ọ.

Bayi, kii ṣe ohun ti o sajeji lati ni oungbẹ. Oungbẹ jẹ ohun kan to ba iwa ẹda eniyan mu. O jẹ ohun kan ti Ọlọrun fun wa lati lee safẹri ohun ti a nilo. Ni igba miran, Ọlọrun pẹlu ti fun ọ ni ọwọn idari, ohun kan ti n sakoso awọn ifẹ orisirisi wọnyi. Oungbẹ yii si jẹ ọwọn isakoso kan to wa ninu eniyan, ohun kan ti Ọlọrun fun

un lati kilọ fun un lati mọ ohun ti o nilo.

11 Bayi, orisi oungbẹ meji ni o wa. Oungbẹ ti ara wa, oungbẹ ti ẹmi si wa pẹlu. Mo fẹ ka ohun ti Dafidi sọ yii lẹẹkan si. "Ọkan mi Poungbẹ fun Ọlọrun, ani fun Ọlọrun alaaye." Kii ṣe ohun itan asan kan, tabi ohun kan to ṣẹlẹ ni ọpọ ọdun sẹyin, tabi itan kan ti ẹnikan sọ - ṣugbọn fun Ọlọrun aaye, Ọlọrun ti o wa nigbogbo igba. Ọkan rẹ si poungbẹ fun Ọlọrun yẹn, kii ṣe ohun itan kan.

12 A ri i wipe, Ọlọrun fi ọwọn isakoso sinu rẹ, lati fun ọ ni ohun ti o nilo. Agbara Isakoso inu rẹ ni o ndari rẹ. Oungbẹ yii si wa sinu agbara Isakoso yii lati sọ ohun ti o nilo fun ọ. Nipa ti ẹmi, agbara Isakoso wa ninu ọkan rẹ. Agbara Isakoso kan wa ninu ara ti o nsọ ohun ti ara nilo. Eyi si ntọ ọ wa nipa oungbẹ. Bẹẹ gẹgẹ, agbara Isakoso kan wa ninu ọkan, ti o nsọ ohun ti o nilo nipa ti ẹmi, o wa ninu ẹmi rẹ. Iwọ sile sọ iru Iye to nsakoso aye rẹ. Nigbati iwọ ba wo ohun ti awọn ifẹ rẹ jẹ, nigba naa, iwọ lee sọ nipa eleyi, iru iye to wa ninu rẹ, ti o nfẹ awọn ohun ti iwọ nfẹ. Wo o, ohun kan wa ti iwọ ni oungbẹ fun, iyẹn si jẹ ki o mọ ohun ti ọkan rẹ nfẹ, nipa iwa ẹda ti iwọ ni. Mo lero pe iyẹn ye ọ.

13 Agbara isakoso kan wa ninu ọkàn, agbara isakoso kan si wa ninu ara. Agbara Isakoso kọọkan ni o si nbeere fun ohun ti o nsafẹri. Ọkọọkan ni o nsafẹri ohun ti o nilo, O ma a nran ikilọ jade. Fun apẹẹrẹ, ara ma a npoungbẹ lati tẹ ifẹ inu ara lọrun, bẹẹ ni ẹmi ma a nsafẹri awọn ohun ti ọkàn nilo. Lọpọ Igba ni ifẹ awọn mejeeji si lodi si ara wọn.

A rii wipe, wahala nla ti ọjọ oni ni pe, ọpọ eniyan ni o ngbiyanju lati gbe laarin ifẹ mejeeji. Nitoripe, ọkan ninu wọn nsafẹri awọn ohun aye yii, ekeji si nsafẹri awọn ohun ti ọrun.

14 Gẹgẹbi Paulu ti ṣalaye rẹ ninu Romu 7:21 "Nigbati mo ba fẹ ṣe rere, nigba naa, ibi wa nibẹ." Nigbati iwọ ba ngbiyanju lati ṣe ohun kan - ṣe iwọ Kristẹni ti ni iriri yẹn ri? - pe, nigbati iwọ ba ngbiyanju lati ṣe ohun kan ti o ṣe Pataki, nigba naa, iwọ yoo rii wipe eṣu wa lọtun losi lati da ọ laamu. Yoo fẹ mu ki ohun gbogbo ti o fẹ ṣe ki o ma ṣeeṣe. Ohun kan ti mo fẹ sọ niyi, ki Kristẹni le mọ: pe nigbati iwọ ba fẹ ṣe ohun kan ti o tọ, ti ohun kan si ngbiyanju lati da ọ lẹkun lati ṣe e, iwọ tẹsiwaju ki o ṣe e lọnakọna. Eṣu ni o wa nibẹ, ti o ngbiyanu lati de ọ lọna lati ṣe ohun ti o tọ.

15 Bayi, lọpọ igba ni mo ma a npade awọn eniyan ti o ni aibalẹ ara. Nigbati wọn ba ri i wipe, wọn ngbiyanju lati ṣe ohun kan, ti ohun gbogbo si nṣe idena si wọn, wọn yoo wipe, "O le ma jẹ ifẹ Oluwa." Ma ṣe jẹ ki eṣu parọ fun ọ bẹyẹn. Ohun akọkọ ni ki o wadi bi ohun naa ba jẹ ifẹ Ọlọrun tabi bẹẹ kọ. Bi iwọ ba si fẹ mọ bi o ba jẹ ifẹ Ọlọrun, wo inu Bibeli. Ohun kan ni o le e tọọ sọna, ohun ni Ọrọ Ọlọrun. Bi iwọ ba si rii pe, o wa ninu Ọrọ Ọlọrun lati ṣe e, fun apẹẹrẹ, wiwa ibaptisimu Ẹmi Mimọ.

Ni ọpọ igba ni mo npade awọn eniyan ti wọn wipe, "Mo ti wa Ẹmi Mimọ, emi ko si ri I gba. Nko gbagbọ pe o wa fun mi. Bi mo ba gba aawẹ, emi yoo saisan. Bi mo ba si gbiyanju lati ṣe aisun, orun yoo kun mi tobẹẹ ti emi ko lee gbe ẹsẹ mi nilẹ". Ranti, eṣu niyẹn, nitori pe Ọlọrun fẹ ki iwọ ni Ẹmi Mimọ. O wa fun ẹnikẹni ti o fẹ.

Ni ọpọ igba, iwọ yoo ri i wipe, bi a ba gbadura fun ọ ninu isin fun imularada, lẹyin naa, ni ọjọ keji, iwọ yoo ri i wipe eṣu yoo mu ki aisan naa buru ni ilọpo meji bi o ti ri tẹlẹ. Ranti pe, eṣu ni o sa ngbiyanju lati mu ki iwọ ya kuro ninu Ibukun ti Ọlọrun ti fifun ọ. Iwọ maṣe feti si ẹda yẹn! Iwọ saa ti tẹsiwaju.

16 Mo ni iriri kan laipẹ ni irinajo mi si Afirika. Bi mo ba ti ni igba kan ti eṣu ti i gbogun ti mi, o jẹ ninu irinajo mi to gbẹyin si Afirika. O si jẹ ọkan ninu awọn ipade ti o dara julọ ti mo tii ṣe ni oke okun ri. Mo gbagbọ pe, mo ni aṣeyọri pupọ ni akoko kukuru yẹn yatọ si igbẹ ọdẹ ti mo ṣe, ju igbakigba lọ.

Mo ti maa nro wipe awọn ijọ yẹn ko fẹ mi nibẹ. Mo wa ri i wipe, mo gba iwe atẹranṣẹ kan lati ọdọ ẹnikan ti o wipe, ah, gbogbo awọn ẹgbẹ ijọ ko fẹ mi, Mo si wa rii wipe, ọkunrin kanṣoṣo ni, ti o ni iwe ti Ijọ kan lọwọ, ti o si fi iwe wọn kọwe wipe, "Awa ko fẹ ọ" ohun ti o ja si ni, 'oun ati ẹbi rẹ'. Nigbati mo de ibẹ, mo ri i wipe, oun ati ẹbi rẹ ni. Kii ṣe awọn eniyan naa rara. Nitori naa, o ti di papa ihinrere nla ti a ṣi silẹ fun wa.

17 O ri i, nigbati Paulu wipe, "Nigbati mo ba fẹ ṣe rere, nigba naa, ibi wa nibẹ"

Iwọ jẹ ki ọdọ kan gbagbọ lalẹ yii, ki o wa sibi pẹpẹ nibi kan, nile isin yii tabi nibikibi ni orilẹ-ede yii. Saa ranti pe ni ọjọ keji, inu yoo bi iya rẹ si i ju bi o ṣe ti ri tẹlẹ ri; inu yoo bi baba rẹ, gbogbo awọn ọmọ ile iwe ni yoo kọ ẹyin sii, ohun gbogbo yoo dojuru, nitoripe satani ngbiyanju lati mu ki o pada. O ngbiyanju lati ti ọ kuro loju ọna. "Nigbati mo ba fẹ ṣe rere, nigba naa ni idaamu yoo wa nibẹ".

18 Bayi, jẹ ki a wo oungbẹ; yala o jẹ ohun ti o ba iwa ẹda mu. Mo ti gbọ ti ẹlomiran wi fun mi pe, "Ah, emi ko ni oungbẹ fun iyẹn. Mo gbagbọ pe awọn kan ni o nifẹsi lati jẹ Kristẹni" Ah, rara. Iyẹn kuna. O jẹ ohun kan ti o nii ṣe pẹlu gbogbo eniyan. Dajudaju otitọ ni.

Nigba ti a wa si orilẹ ede yii fun igba akọkọ, a ba awọn India nibi. Bi o tilẹ jẹ wipe awọn India jẹ Keferi ni akoko naa, (wọn nsin oorun tabi ohun miran) niwọn igbati wọn jẹ eniyan, ohun kan wa ninu wọn, oungbẹ kan nmu ki wọn kigbe si Ọlọrun nibi kan.

19 Ninu Igbo kijikiji laipẹ yii, nibiti o jẹ ẹẹdẹgbẹta mẹẹli o din ogun si ilu ọlaju ti o sunmọ julọ, ilu kekere kan wa ti o ni eniyan bi ẹgbẹrun mẹta ni Beira ni Mozambique, a ri awọn ara ilẹ naa, ti wọn ko ri eniyan alawọ funfun ri. Mo ri ọmọbinrin ara ilẹ naa kan (ko si wọ aṣọ kankan - sasa ni o wọ aṣọ ninu wọn) ọmọbinrin naa joko si ori igi, emi si ntọpasẹ kiniun kan, mo si gbọ ohun kan bii ti eniyan to nkigbe, ọmọbinrin ti o joko sinu igi loke yii paruwo, o si gbe ọmọ kan lọwọ. Ohun ti o ba lẹru ni wipe o ri mi, eniyan funfun ti ko ri ri. Ọna kanṣoṣo ti oun si ni lati daabo bo ara rẹ niyẹn - lati gun igi lọ - ki o le sa fun kiniun ati amọtẹkun tabi ẹranko miran. Ko ti i ri eniyan funfun ri laye rẹ, ẹru si ba a doju iku.

Ṣugbọn nigbati a ri awọn eniyan naa, pẹlu ipo aimọkan ti wọn wa, wọn n sin ohun kan sibẹ. Ki a to le kiniun kan wọle, wọn da ounjẹ kan (ohun ti wọn njẹ nibẹ) si ori ewe, wọn patẹwọ, wọn si pe ẹmi ohun nla kan (wọn ko mọ ibiti o ti wa, gẹgẹbi ẹmi ẹni atijọ mimọ kan bii ti Katoliiki) lati daabo bo wọn, pe ki wọn ma ba a ku ni akoko ti kiniun naa ba jade sita.

20 Se o rii, ohun kan ti o ba iwa ẹda waye ni.

Kii ṣe ohun kan to sajeji lati ni oungbẹ fun Ọlọrun, ohun ti o ba ẹda mu ni. O jẹ ohun kan ti o yẹ ki o ṣe. Bi Ọlọrun ṣe da ọ niyẹn. Ko si wa fun awọn eniyan nla to tayọ kan; nitootọ, o wa fun ẹnikẹni. Kii ṣe ohun to wa fun kiki awọn titayọ kan. Wọn a wipe, “Mo ti ri awọn eniyan kan ti wọn gbe igbe aye iṣẹgun to bẹẹ, ti wọn maa nwa lori orule nigba gbogbo. Wọn nyin Ọlọrun logo. O wu mi ki emi naa ri bi iyẹn.” O dara, idi ti iwọ fi nifẹ si iyẹn ni oungbẹ ti o wa ninu rẹ. O si jẹ ohun ti o ba ẹda mu. O wa fun gbogbo eniyan lati ni oungbẹ fun Ọlọrun. 19:49

21 Bayi, a o sọ nipa oungbẹ ti ara ṣaaju. Jẹ ki a mu oungbẹ fun omi, bi Dafidi ti sọ nibi yii. Ara nilo omi. Bi iwọ ko ba si fun ara ni omi, iwọ yoo ku. Iwọ yoo gbẹ, iwọ yoo si ku. Bi iwọ ko ba fi omi fun oungbẹ yẹn ti ara beere fun, iwọ yoo ku. O ko ni wa laaye pẹ.

Iwọ le wa laaye lai jẹ onjẹ ju ki o má mu omi lọ. Nitori pe, iwọ lee gbawẹ fun ogoji ọjọ. Jesu ṣe bẹẹ laijẹ ounjẹ kankan, ṣugbọn iwọ ko lee ṣe iyẹn lai mu omi. Iwọ yoo gbẹ, ó si ku. O nilani ni omi. Oungbẹ ti iwọ si ni, o jẹ lati sọ fun ọ ohun ti ara rẹ nilo lati wa laaye. Ara nilati ni omi lati wa laaye. Omi ko ipa to ju ida mẹrin ninu ida marun ara, o si nilati ni ohun yii lati wa laaye. Gẹgẹ bi mo ti sọ, bi iwọ ba kọ lati fun ara ni omi, iwọ yoo ṣegbe.

Oungbẹ pẹlu jẹ igbe ikilọ tabi itaniji kan. Ọkan rẹ ninu rẹ yoo ṣe itani-giri kan ninu rẹ, yoo kilọ fun ọ pe, iku ko jina si ọ, pe bi iwọ ko ba ri omi laipẹ, iwọ yoo ku. Igbe naa yoo si maa pọ si, bi iwọ ba si dagunla si igbe ikilọ naa, iwọ yoo ku. Nitoripe, agogo ikilọ ni.

22 Gẹgẹ bi Dafidi ti ṣalaye rẹ ninu Psaamu: “Bi agbọnrin ti nmi hẹlẹ si ipado omi, bẹẹ ni ọkan nmi hẹlẹ si ọ, Ọlọrun.” Bi agbọnrin ti nmi hẹlẹ si ipado omi. Mo ti maa nronu nipa Dafidi nigba ti mo ba ka Saamu yii. Dafidi jẹ ẹniti nlo ọpọ akoko rẹ ninu igbo, o jẹ ọdẹ, o si ndọdẹ agbọnrin dajudaju. Awa pẹlu ndọdẹ agbọnrin lọjọ oni. Agbọnrin ni o darukọ yii.

A si rii wipe, bi iwọ ba ti ri awọn aja ọdẹ ri, wọn yoo gba agbọnrin mu. Wọn si ni ẹyín ti o mu, o si lee gba agbọrin mu ni ẹyin eti rẹ, yoo si fi agbọnrin naa. Oun yoo si bu ọrun agbọnrin naa, ko si lee sa lọ nigba naa.

Ṣugbọn nigbamiran, aja yẹn, gẹgẹ bi i ni Afirika, aja ọdẹ yoo fi ẹyin gba itan agbọnrin mu, bi ko ba ri aye buu jẹ ni gogongo, yoo bu itan rẹ jẹ. Bi agbọnrin ba si lagbara to, yoo ja ara rẹ gba.

23 Agbọnrin yara pupọ ju aja lọ. Aja maa nyọ kẹlẹkẹlẹ lati mu agbọnrin ni, nigbati ko ba kiyesara, ti o si wa nibiti atẹgun ko ti tu aṣiri aja naa fun, pe o ti wa nitosi. Nigbati aja ọdẹ ba si gbamu lojiji, bi o ba le yara, ti o si lagbara, o le ja ara rẹ gba.

Ṣugbọn bi aja yii ṣe ja kuro, o ti bu ẹran ara rẹ si ẹnu. Tabi nigba ti o ba bu ọrun rẹ nigbamiran, oun ti bu ẹran ọrun diẹ ti ko de gogongo agbọnrin. Nigbati agbọnrin si ti ja ara rẹ gba, aja yii ti bu ẹran ọrun rẹ, ẹjẹ yoo si bẹrẹ sii da. Aja yoo si sa tẹlẹ agbọnrin naa. Bi ẹjẹ ti nda lara agbọnrin, ni iye rẹ yoo maa dinku diẹdiẹ, yoo maa rẹ ẹ. Aja naa, tabi ikooko si wa lẹyin rẹ.

Bayi, bi agbọnrin naa ko ba ri omi….. Omi ni ohun kan ninu rẹ ti o jẹ wipe, bi agbọnrin ba ti mu omi, ẹjẹ yẹn yoo dẹkun lati maa da lara rẹ. Ṣugbọn bi oun ko ba ri omi lati mu, ẹjẹ yoo tun maa da lara rẹ si, nitori pe o nsare, ọkan rẹ si n mu ki ẹjẹ sa kaakiri ara rẹ. Ṣugbọn bi oun ba ri omi mu agbọnrin naa yoo ye.

24 Bayi, ẹkọ nla kan wa nibi yii, ti Dafidi sọ nibi yii pe, “Bi agbọnrin ti nmi hẹlẹ si ipado omi, bẹẹ ni ọkan mi

nmi hẹlẹ si Ọ, Ọlọrun.” Agbọnrin yẹn mọ wipe, bi oun ko ba ri omi mu, iku ti de. Ko lee ye. Mo ti tọpasẹ wọn ni ọpọ igba. Lẹyin ti o ti ni ijamba, nigbati o ba ti de odo sisan kan, oun yoo re odo naa kọja si odikeji, yoo si mu omi, yoo si gun oke diẹ, yoo tun pada si odo naa, yoo re e kọja, yoo si mu omi, yoo gun oke. Iwọ ko lee baa lọna mọ, niwọn igbati o ba ti tẹle odo omi sisan yẹn. Ṣugbọn bi o ba fi odo silẹ, laipẹ aja yoo ba a. Agbọnrin naa mọ iyẹn, nitori naa, yoo duro ti omi odo yẹn nibiti oun ti le tete mu omi kiakia.

Se o lee ro nipa agbọnrin kan ti o gbe imu rẹ si oke; ti wọn ti ka mọ ibikan ti ko ni omi.

25 O si wipe, “Bi agbọnrin ti nmi hẹlẹ ti o npoungbẹ si ipado omi, ọkan mi npoungbẹ fun Ọ, Ọlọrun. Bi emi ko ba ri Ọ, Oluwa, emi yoo ṣegbe. Emi ko lee lọ bi emi ko ba ri Ọ” Nigbati ọkunrin tabi obinrin kan, ọmọkunrin tabi ọmọbinrin ba si ni iru oungbẹ bẹẹ fun Ọlọrun, Oun yoo ri ohun kan gba.

Ṣugbọn nigbati a ba nwa Ọlọrun lai fi gbogbo ọkan wa A, “O dara, emi yoo kunlẹ, n o si wo ohun ti Oluwa yoo ṣe” Woo, oungbẹ ko tii gbẹ ọ gidi. O nilati jẹ oungbẹ ti iwọ wa laarin iye ati iku. Nigba naa ni ohun kan yoo ṣẹlẹ.

26 Agbọnrin tun ni onmọ ara miran lati gboorun nigba ti ọta rẹ ba sunmọ tosi. A fun ẹda kekere yii ni onmọ lati daabo bo ara rẹ. Oun si ni agogo ikilọ kan ninu rẹ, onmọ kan ti yoo kan imu rẹ nigbati ọta ba sunmọ ọn. Bi iwọ ba sunmọ ọn, bi o ba ti gboorun rẹ, yoo ti mọ pe ewu wa, lọgan ni yoo sa lọ. Nigbamiran, ni ilaji ibusọ jinna sọdọ rẹ yoo ti mọ, yoo si salọ. O le jẹ ikooko tabi ewu miran, oun lee mọ ọn, nitori bi a ṣe daa niyẹn. Agbọnrin ni iwa ẹda yẹn. Onmọ igboorun yii jẹ ọkan ninu awọn onmọ ara, ti Ọlọrun fifun un lati fi wa laaye.

27 Lẹyin naa, mo roo, bi mo ṣe nfi agbọnrin we eniyan kan ti oungbẹ ngbẹ fun Ọlọrun. Ki ọta to de, ohun kan wa nipa ọmọ Ọlọrun kan ti a ti tunbi nipa Ẹmi Ọlọrun; ti o si ti gba Ẹmi Mimọ, ohun kan wa nipa rẹ ti o lee mọ pe ọta ti sunmọ tosi. O le mu ẹnikan, bi o ti n ka Iwe Mimọ, ti o si ngbiyanju lati fi oun kan ti o lodi si Iwe Mimọ sinu rẹ. Ẹnikan ti a ti kun fun Ẹmi Mimọ le mọ iyẹn lọgan. Ohun kan ti lodi. A fun ọ ni onmọ yẹn lati daabo bo ẹmi rẹ. Iwọ ko gbọdọ gba ohunkohun ti o ba yatọ diẹ si Ọrọ Ọlọrun. O nilati duro patapata pẹlu Ọrọ yẹn. A si ni ipamọ nipa onmọ yẹn, niwọn igbati a ba wa ninu Ẹmi Mimọ.

28 Bi iwọ ba nka Ọrọ Ọlọrun, fun apẹẹrẹ, bi o ba ka Marku 16 ti o wipe, “Ami wọnyi ni yoo ma a ba awọn ti o gbagbọ lọ. Ni orukọ Mi ni wọn yoo le ẹmi eṣu jade. Wọn yoo fi ede titun sọrọ, tabi gbe ejo ni ọwọ, tabi mu ohun oloro, ki yoo si pa wọn lara. Bi wọn ba gbe ọwọ le alaisan, a o mu wọn larada”

Bayi, bi o ba ri ẹnikan ti o wipe, “Bayi, iyẹn wa fun iran awọn aposteli nikan” Bi iwọ ba ti gba Ẹmi Mimọ, lẹsẹkẹsẹ, a ti fun ọ ni onmọ yẹn - yoo kigbe wipe, ohun kan kuna nibẹ yẹn. Wọn ngbiyanju lati fi itumọ ṣe aigbagbọ si ọrọ yẹn wipe, “Iyẹn wa fun ọjọ miran. Nitootọ, iwọ ko nilo iyẹn loni”

Ṣugbọn Jesu wipe, “Ami wọnyi ni yoo maa ba awọn to gbagbọ lọ” Ohun kan yoo lu agogo ikilọ ninu rẹ, ti o mu ọ mọ wipe, iyẹn kuna. Ọna iku si ni yẹn.

29 Nitoripe Jesu wipe, bi ẹnikẹni ba fi ọrọ kan kun ọrọ yii, tabi mu ọrọ kan kuro ninu rẹ, a o mu ipa ti ẹni naa kuro ninu Iwe Iye. A ko gbọdọ yọ ọ̀kan kuro - a nilati gba a bi a ṣe kọ ọ gẹlẹ. Ọlọrun si nwo Ọrọ Rẹ lati mu U ṣe. A mọ pe o nilati jẹ otitọ.

Nitori naa, ohunkohun ti ijọ kan le sọ, ti ẹnikẹni le sọ, bi a ba ti bi ọ nipa Ẹmi Ọlọrun, iwọ di ara Bibeli. Ọlọrun sọ fun Esekieli (wolii kan nii ṣe) wipe, “Mu Ọrọ naa, ki o jẹ ẹ” Nigba naa ni wolii naa ati Ọrọ naa di ẹyọ kan. Iyẹn si ṣẹlẹ si onigbagbọ nigbati o ba ti gba Ẹmi Mimọ. Ẹmi Mimọ ni o kọ Bibeli. Ẹmi Ọlọrun si ni Ọrọ Ọlọrun. “Ọrọ Mi jẹ Ẹmi” Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa. Ọrọ naa si wa pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun si ni Ọrọ naa. Ọrọ naa si di ara, O nba wa gbe. Heberu 13:8; Oun jẹ ọkan naa lana, loni, ati titi Lae. Nigbati Iwọ ba si ti di ara Ọrọ naa, jẹ ki ohun kan wa ti o lodi si Ọrọ yẹn, agogo ikilọ kan yoo dun kia. O wa nibẹ lati kilọ fun ọ wipe iku ti nbọ lọna. A ko gbọdọ ṣe iyẹn.

Oungbẹ wọnyi ba ẹda mu. Wọn ba ẹda Kristẹni mu. Wọn ba iwa ẹda eniyan mu.

30 Oungbẹ wa fun aṣeyọri pẹlu. Ọpọ eniyan loni ni wọn nkawe fun oungbẹ yii. A ri i wipe, wọn ti nkọ ẹkọ naa ni ile iwe giga Yunifasiti. Awọn eniyan si lọ sibẹ, wọn na ẹgbẹgbẹrun dọla lati ran ọmọ wọn lọ sile iwe giga lorisirisi, wọn si wipe, ki wọn le ṣe aṣeyọri ni aye.

Emi ko ni ohunkohun lodi si iyẹn. Bayi, iyẹn dara. Ṣugbọn niti emi, iwọ lee ka gbogbo iwe ti o wa laye, sibẹ, ki o ma ni aṣeyọri ti o tọ. Bẹẹni, Nitoripe, iyẹn yoo sa mu ki nkan dẹrùn diẹ fun ọ fun igba diẹ nibi yi ni. Sugbọn nigbati iwọ ba ku, iwọ yoo fi gbogbo rẹ silẹ.

31 (Emi nsọ eleyi ni Phoenix nijelo, o si yẹ ki n tun sọ) wipe gbogbo ọlaju igbalode, eto ẹkọ ile iwe, eto imọ ijinlẹ, gbogbo wọn ni o lodi si Ọrọ Ọlọrun, ati ifẹ Rẹ.

Ọlaju jẹ ti eṣu patapata, ki yoo si ọlaju ni aye ti nbọ wa, bi eleyi. Ọlaju to dibajẹ ni eleyi. Ọlọrun ni ọlaju

Rẹ akọkọ ni aye nigbati O sọ Ọrọ Rẹ, ti wọn si ṣẹlẹ, ti olukuluku iru si mu eso ara rẹ jade. Ninu ọlaju yẹn, ko si iku, aisan ati ibanujẹ. Bayi, bi a ba mu awọn nkan ti imọ ijinlẹ, ti wọn fi sibi lati dibajẹ ohun ti o wa si ohun miran, ti o si mu iku de. Fun apẹẹrẹ, ado oloro, emi ko mọ bi wọn ti ṣe e. Ẹ jẹ ka sọ wipe, wọn mu eroja yureniọmu, wọn si pin ẹya rẹ to kere julọ, kin ni o nṣe? O nfọ gbogbo nkan si wẹwẹ, o nparun.

Gbogbo ohun ti a nṣe……….

32 Bi a ba mu oogun iwosan, a mu ohun kan, a poo pọ mọ omiran, lati fi wo aisan yii san, a si fi sinu ara wa. Kin ni a si ṣe? A pa ohun miran run ninu ara wa. Mo ro pe ẹ ka iwe iroyin atigbadagba "Readers Digest" ti oṣu to kọja, pe o sọ iyẹn, pe ninu aye yii bayi, awọn ọdọkunrin ati ọdọbinrin nde ilaji aye wọn ni ẹni ogun ọdun si ọdun marundọgbọn. Ronu nipa iyẹn! Awọn ọmọbinrin kekeke nde akoko iyipada aye, ti wọn ko lee ri ami oṣooṣu mọ ni ọmọ ogun ọdun si mẹtalelogun. Wọn ti de irolẹ aye wọn!

Se o ri ohun ti o fa a? O jẹ awọn onjẹ adamọdi wọnyi ti a njẹ. O jẹ ounjẹ naa, oogun ti a nlo ati igbe aye ti a ngbe. Awọn onimọ ijinlẹ ti mu wọn wa fun wa, ati nipa bẹẹ, wọn npa yin. Mo wa ni Afirika nibiti mo ti ri awọn ọmọkunrin ti ko lo oogun kankan ri laye wọn. Wọn jẹ ẹran to ni idin ninu rẹ. Wọn mu omi lati inu omi adagun ti o dabi pe yoo pa maluu. Mo si nta ibọn si ohun kan ni igba yaadi, emi ko si ri i pẹlu awò dígí to nsọ nkan di nla. Ọkunrin kan ti a jọ jẹ ẹgbẹ lọjọ ori si wa nibẹ ti o nwo kedere pẹlu oju tirẹ lailo awo diigi kankan. Bayi, gbogbo nkan ọlaju yii ti ṣe iṣẹ kan. Mo ro pe, o san ki n ni oju ti ọkunrin yii ati ikun rẹ. Iba san fun mi! Ṣugbọn ẹ wo aye wa.

Se o rii, ohun ti imọ ijinlẹ, imọ iwe, ati ọlaju ti ṣe niyẹn. A ti n pawarun nipa rẹ. O npa ara wa. O bẹrẹ ninu ọgba Edẹni, o si tẹsiwaju titi di oni. Ṣugbọn ninu oungbẹ fun aṣeyọri…….

Lẹyin naa, a n poungbẹ fun idapọ. A fẹ idapọ.

33 O dabi ọdọkunrin kan ati ọdọbinrin kan. Kii ṣe ohun ti o buru ki ọdọkunrin kan ati ọdọbinrin kan ni ifẹ ara wọn. Oungbẹ fun ifẹ ni. Ọjọ ori wọn ati akoko wọn ni. Wọn nifẹ ara wọn, ki i si ṣe ohun to buru. Ohun kan to ba ẹda mu ni fun wọn lati ṣe.

A ri ọpọlọpọ nkan ninu aye ti a ngbe ti a ni oungbẹ fun. Ohun kan ti a fi sinu wa ni, ti a nifẹ lati ṣe. A ni imọlara patapata pe a nilati ṣe e, o si yẹ ki a ṣee. A ri ọpọ awọn obinrin loni to ni oungbẹ lati lẹwa. Iyẹn jẹ onmọ kan ti Ọlọrun fun un, ati ẹwa ti a fun un fun ọkọ rẹ. A si rii pe awọn obinrin fẹ ṣe bẹyẹn. Tori kin ni? O jẹ nitori ohun kan ti Ọlọrun fi fun un. Ko kuna fun obinrin lati ni ẹwa. O yẹ ki wọn ṣe bẹẹ.

34 Ẹ si mọ pe, awọn nikan ni ẹda Ọlọrun ti abo rẹ lẹwa ju akọ lọ. Ẹda eniyan nikan ni o ri bẹẹ. Gbogbo ẹranko ti o ku - iwọ wo maluu ati akọ-maluu, abo agbọnrin ati akọ rẹ, abo adiyẹ ati akukọ, akọ ẹyẹ ati abo ẹyẹ - nigba gbogbo, a rii wipe akọ ni o tobi, ti o si lẹwa ju. Ṣugbọn ni ti ẹda eniyan, o yatọ (o fihan pe nibẹ ni idibajẹ ti ṣẹlẹ) obinrin ni o lẹwa ju, wọn lẹwa pupọ wọn si ṣe ifẹkufẹ lati lẹwa.

Kii ṣe bi awọn ẹda to buru ni wiwo ti a nri loju popo wa loni. Rara, rara! Kii ṣe iru ẹwa yẹn, rara! Iyẹn jẹ awọn ohun ti o buru ni wiwo julọ ti mo ti ri ri laye mi. Bẹẹni, sa! Idibajẹ ni wọn yẹn. Idibajẹ oungbẹ tootọ.

35 Bayi, oungbẹ tootọ ti o yẹ ki obinrin ni, ni pe ki o fi iwọntuwọnsi wọ aṣọ, ki o si ni ẹmi bi ti Kristi Timoti Kinni, 2:9 Bi o ṣe yẹ ki obinrin ni oungbẹ lati jẹ niyẹn. Bi iwọ ba fẹ ni ẹwa, ohun ti yoo mu ọ ni ẹwa niyẹn, ohun ni ẹmi bii ti Kristi pẹlu iwọṣọ iwọntuwọnsi.

Ah, ah, ah! Awọn eniyan ọjọ oni yi! Ni oju titi, o ṣoro lati da obinrin mọ yatọ si ọkunrin. O si jẹ ohun to buru ni wiwo julọ. Mo fẹrẹ ma ri ohun bẹẹ ri, ti yatọ si eniyan tootọ, awọn oju ti wọn fi ọda kun, ti wọn dabi oju alangba, ati awọn aṣọ to buru lati wọ. Gbogbo ifarahan wọn buru pupọ, wọn ko jọ eniyan mọ. Awọn ọmọkunrin si din irun ori wọn pẹlu awọn ohun elo irun ẹ̀gbọ́n wọn obinrin niwaju bayi, o ye yin - o si jẹ idibajẹ patapata! Otitọ niyẹn!

Satani ni, oludibajẹ si ni Satani.

36 Nigbati Ọlọrun da ohun gbogbo ninu ọgba Ẹdẹni, ohun gbogbo dara. Nigba naa ni satani wa, o si dibajẹ rẹ. Satani ko lee da ohunkohun. Ẹlẹda kan ṣoṣo ni o wa. Ọlọrun si ni. Ṣugbọn Satani ndibajẹ ẹda ti Ọlọrun ti da ni ojulowo. Bayi, o si ti wa dibajẹ ohun ti mo nsọ lalẹ yii, o ti dibajẹ ohun ti Ọlọrun da ojulowo rẹ.

Gẹgẹbi mo ti sọ, obinrin fẹ ni ẹwa. Ohun kan wa ninu rẹ ti o jẹ abo. O si fẹ ṣe bẹyẹn. Ṣugbọn, bi wọn ti ri loju titi loni, ti o gerun rẹ bii ti ọkunrin, ti o wọṣọ ọkunrin, ti awọn ọkunrin si yipada, ti wọn nwọṣọ obinrin, ti wọn ṣe irun bi ti obinrin. Wo o, idibajẹ ni, alupayipda ni gbogbo rẹ. Ounjẹ rẹ ti dibajẹ, iye ati igbe aye rẹ ti dibajẹ, oungbẹ rẹ ti dibajẹ, ifẹ ọkan yin ti dibajẹ - ọjọ idibajẹ ni a wa.

37 Mo nsọrọ ni ijelo nipa Edẹni Satani. Ọlọrun lo ẹgbẹrun mẹfa ọdun lati da Edẹni pipe. Satan si wa, o fọn majele idibajẹ le ori awọn iru naa, o si dibajẹ wọn. Bayi, o ti lo ẹgbẹrun mẹfa ọdun ninu iṣẹ idibajẹ rẹ, o si ti

wa ni Ẹdẹni ti onimọ ijinlẹ. Eyi si jẹ iran ti adamọ iru. Wọn tilẹ ti ṣe adamọdi Ijọ pẹlu loni. Bẹẹni.

Awọn eniyan sa nlọ sile isin lasan. Ile ẹgbẹ lasan ni, kii ṣe Ijọ. Ijọ jẹ ibikan ti awọn eniyan nkora-jọpọ si, lati sin Ọlọrun ni Ẹmi ati ni otitọ. Loni, o si ti di ile ẹgbẹ awo lasan. A lọ sibẹ lati lọ bọ ara wa lọwọ, a ni ijọsin, a si jọ mu kọfi dudu ni ẹyin ile, a o si lọ sile, o tun di ọsẹ miran. A ti ṣe iṣẹ isin wa fun ọsẹ kan niyẹn. Iran idibajẹ ni. Satani si ndibajẹ awọn oungbẹ wọnyi ti Ọlọrun fi sinu wa lati ni oungbẹ. Satani lo ndibajẹ wọn.

Bayi, bi iwọ ba fẹ mọ oungbẹ ti o tọ́.

38 Bi obinrin ba fẹ lẹwa, ki o mu Timotiu kinni 2:9. Eyi ni ki obinrin wọṣọ pẹlu iwọntuwọnsi, pẹlu ẹmi to dabi Kristi, iwatutu, ti o wa ni itẹriba fun ọkọ wọn ati bẹẹ bẹẹ lọ. Bi o ṣe nilati ṣe ẹṣọ niyẹn, nipa igbe aye rẹ. Satani ndibajẹ iwa-ẹda Ọlọrun tootọ, ati oungbẹ tootọ ti Ọlọrun da fun ara ati ọkan, nipa siṣe ifẹkufẹ si ẹṣẹ, idibajẹ ni.

Bayi, a rii wipe, ọna ti wọn fi dibajẹ ohun gbogbo ni oni - oungbẹ fun Ọlọrun, oungbẹ lati lẹwa, titi mọ oungbẹ fun omi - wọn ti dibajẹ iyẹn nipa mimu ọti lile. Oungbẹ fun ayọ - gbogbo eniyan lo fẹ ni ayọ. Oungbẹ fun idapọ, gbogbo awọn oungbẹ nla ti Ọlọrun fi sinu wa wọnyi, ki awa lee poungbẹ fun Ọlọrun. Ọlọrun da ọ lati poungbẹ fun ara Rẹ. Awa si ngbiyanju lati tẹ oungbẹ naa lọrun pẹlu awọn ohun miran, pẹlu idibajẹ ti oungbẹ tootọ. Wo bi o ti ri nipa ti ara? Wo bi o ti ri nipa ti ẹmi? A ro wipe, bi a ba ti darapọ mọ Ijọ, o ti dara, ohun ti a nilati ṣe gẹlẹ niyẹn. Iyẹn kuna patapata. Rara, Ọlọrun fẹ ki iwọ poungbẹ fun Un. Bi agbọnrin ti nmi hẹlẹ si ipado omi, bẹẹ ni ọkan mi npoungbẹ fun Ọ, Ọlọrun. Ṣe o rii?

39 Bayi, bi agbọnrin ti nmi hẹlẹ si ipado omi, bi ẹnikan ba wa (agbọnrin miran) ti o wa sọ fun un wipe, “Wo o, jẹ ki nsọ ohun ti mo lee ṣe. Mo mọ ibikan ti abata kan wa nisalẹ yẹn” Agbọnrin yii ko ni feti si iyẹn. Iyẹn ko lee ṣe e ni anfaani rara.

Ko si si ohun ti o lee tẹ oungbẹ ti o wa ninu eniyan lọrun bikoṣe ki Ọlọrun wọ inu rẹ. O nilati ni Ọlọrun tabi ki o ku. Ko si si ẹnikẹni ti o ni ẹtọ lati pa oungbẹ mimọ yẹn tabi ki o fi ohun aye tẹ ẹ lọrun. Rara, sa! Aiwabi-Ọlọrun ni lati ṣe bẹẹ. Bi oungbẹ Ọlọrun ba si ngbẹ ọ, iwọ ma ṣe lọ bọ oniwaasu lọwọ tabi kọ orukọ rẹ sinu iwe ọmọ ijọ kan. Bi oungbẹ Ọlọrun ba ngbẹ ọ, ohun kanṣoṣo ni o le tẹ ọ lọrun: Iyẹn ni ki o ba Ọlọrun pade. Bi iwọ ba poungbẹ fun Ọlọrun; ohun kan ṣoṣo ti iwọ nilati ṣe niyẹn; ohun ni ki o ba Ọlọrun pade.

40 Ewu kan si wa pẹlu, bi iwọ ko ba kiyesara ni akoko naa. Bi oungbẹ Ọlọrun ba ngbẹ ọ, rii daju pe Ọlọrun ni o ba pade. Rii daju pe a tẹ oungbẹ rẹ lọrun.

Ṣugbọn, bi Satani ba ti lee dibajẹ rẹ nipasẹ awọn ifẹ ti ara wọnyi - ohun ti yoo si ṣe niyẹn bi o ba ṣeeṣe - oun yoo fun ọ ni itẹlọrun idakọnkọ. Ohun ti o mu ki eniyan mu ọti yo ni wipe, o nwa itẹlọrun; o ni idaamu, inu rẹ ko si dun. Ohun kan sọnu ninu rẹ ti o nilo.

41 Mo wa ni Ile Itọju alaisan Mayo ni igba kan. Mo si wa nibẹ fun ifọrọ-wani-lẹnu-wo. A nsọrọ nipa ọti mimu. Mo sọ fun wọn pe, baba mi mu ọti. Wọn wipe, “Kin ni o mu ki o muti?

Mo wipe, “Emi ko mọ”

O dahun pe, Idi nipe, ohun kan wa ti ko tẹ ẹ lọrun, o si ro wipe, oun le muti lati mu un kuro lọkan.“

O ye mi lẹsẹkẹsẹ. Ọlọrun nikan ni o le tẹ oungbẹ yẹn lọrun. Ohun kan ṣoṣo ti o lee tẹ oungbẹ ọkan eniyan lọrun ni ki o gba Ọlọrun sinu ọkan yẹn.

42 Bayi, gẹgẹbi mo ti sọ, Satani nmu nkan wọnyi, o si ndibajẹ wọn. Nigba naa, bi iwọ ko ba kọbi-ara-si oungbẹ naa, ti iwọ ko si fi Ọlọrun ṣe itẹlọrun oungbẹ rẹ; satani yoo dari rẹ lọ si adagun omi onidọtin ti aye yi kan lati fun ọ ni itẹlọrun.

O nilati ba oungbẹ yẹn pade nibikan. Bi iwọ ko ba ri ounjẹ jẹ, iwọ yoo sa ounjẹ jẹ nibiti wọn da ilẹ idọti si. Bi iwọ ko ba si ri omi mu, ti iwọ si nku lọ, iwọ yoo mu omi lati inu adagun omi-komi, nitoripe o ti nku lọ. Ṣugbọn ko si idi fun iyẹn bi iwọ ba n poungbẹ fun Ọlọrun, nitoripe Ọlọrun alaaye ni - kii ṣe ohun itan kan. Ọkan mi n poungbẹ fun Iwọ Ọlọrun alaaye, oun kan ti nfun ni lomi iye, ohun ti ntẹnilọrun.

43 Iwa ẹda miran wa ninu ọkan ti o ma a nni oungbẹ. Iwọ le wipe, “Arakunrin Branham, ṣe oungbẹ ọkan yẹn wọpọ, ṣe gbogbo eniyan ni o ni in?' Bẹẹni, ohun to ba ẹda mu ni fun ọkan lati ni oungbẹ. Ọlọrun da ọ ni ọna yẹn, ki iwọ le ni oungbẹ fun Ọlọrun. O fẹ ki o safẹri Oun.

Bayi, Ọlọrun da ọ bẹẹ. Oun ko nilati da ọ bẹẹ, ṣugbọn O da ọ bẹẹ. Bi o ba ṣe wipe, Oun ko da ọ ni ọna yii ni, iwọ iba ni awawi nibi itẹ idajọ wipe, “Emi ko poungbẹ fun Ọlọrun ri.” Ṣugbọn ko si awawi. Iwọ poungbẹ. Iwọ yoo tẹ oungbẹ yẹn lọrun ni ọna kan tabi ekeji. Iwọ le wa itẹlọrun ninu Iyawo rẹ, o le jẹ ọkọ̀ ayọkẹlẹ rẹ, o le fi ṣe ohunkohun, o le fi ṣe lilọ sile isin rẹ. Emi ko si ni ohunkohun lodi si lilọ si ile-isin, ṣugbọn iyẹn kọ ni

itẹlọrun naa. O jẹ pe, ki o wa Ọlọrun ri, Ọlọrun alaaye, Ọlọrun Ọrun sinu Ọkan rẹ ti yoo fun ọkan rẹ ni itẹlọrun ohun gbogbo ti iwọ npoungbẹ fun. Nitori O da ọ pe, ki iwọ ni oungbẹ fun Un, ati idapọ pẹlu Rẹ.

Bayi, oungbẹ tootọ fun idapọ pẹlu wà. A nifẹ lati ni ipade pẹlu ara wa. A n ṣe iyẹn lalẹ yii. A pade papọ lalẹ yii nitoripe a nifẹ si idapọ, lati ṣe ipade pẹlu ara wa. Kin ni idi eleyi? Nitoripe ohun kan wa ninu wa ti o fẹ ṣe ipade pẹlu ẹnikeji. Iyẹn ba iwa- ẹda mu. A si wa pade ara wa nibi nipa ohun kan ti a ni papọ. Eyi jẹ nitoripe gbogbo wa ni o n poungbẹ fun Ọlọrun.

Nigba naa, a pade nibi nitori idapọ ti a ni papọ. Nile isin lalẹ yii, ọpọ orisirisi igbagbọ ijọ ni o le wa, ṣugbọn, bi o ba ṣe ti oungbẹ yẹn, a le pade lori koko kan naa ti gbogbo wa ni, wipe gbogbo wa ni o ni oungbẹ. Awọn diẹ lo gbagbọ ninu bibu omi wọn ni, awọn miran le gbagbọ ninu itẹbọmi, awọn kan dida omi le eniyan lori, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ṣugbọn nigbati o ba di ti oungbẹ fun Ọlọrun, a ni iyẹn papọ sọkan. Ọlọrun si da wa ki a lee ṣe iyẹn, ki a poungbẹ fun Un ati idapọ pẹlu Rẹ.

44 Nigbati mo jẹ ọmọkunrin kekere, mo ranti pe a tọ mi ni ile ti o talaka pupọ. Mo si ranti ọpọ igba ti mo jade lọ pẹlu awọn eniyan. Emi ko le wọ aṣọ ti mo nilo lati lọ si awọn ibiti o dara. Ṣugbọn, ohun kan wa nipa awọn eniyan ti mo fẹran. Mo fẹran lati ba wọn pe, ṣugbọn, mo sa jẹ ẹniti ko le ba ẹgbẹ pejọ. Nigbati a si gbamila, mo ri oun naa ninu mi ti mo ti ni oungbẹ fun yẹn, ọrẹ kan - ẹnikan ti o jẹ ọrẹ to duro timi, ẹnikan ti mo lee gbẹkẹle, ẹnikan ti o lee joko pẹlu lati sọ gbogbo iṣoro rẹ fun. Nigbati mo si ri itẹlọrun tootọ yẹn, ti mo ri Jesu Kristi, tii ṣe itẹlọrun tootọ to ntan gbogbo oungbẹ, to nfun ọ ni ohun ti ko ni afiwe kankan.

45 Bi eṣu si ṣe maa ngbiyanju lati ṣe alupayida itẹlọrun ọkan yii, oungbẹ ọkan yẹn. Satani maa ngbiyanju lati fun ọ ni ohun gbogbo lati tẹ oungbẹ yẹn lọrun, oun si kun fun ẹtan pupọ ni akoko idibajẹ yii. Aye ti o ti dibajẹ ni. O jẹ awọn eniyan ti o ti dibajẹ. Ohun gbogbo ni o ti dibajẹ. O si ti ṣe idibajẹ naa diẹ-diẹ, to bẹẹ, ti o fi jẹ iran ti o ni ẹtan julọ ti o ti wa ri. O ni ẹtan ju eyikeji ti o ti wa ri lọ. Iwọ ko tilẹ lee roo wo, bi awọn orilẹ-ede ti kan fun ẹtan to, titi mọ awọn ara wa, awọn eniyan Amẹrika.

46 Mo wa ninu Igbo ni ijelo, mo si ri paali siga kan ti o wa nilẹ ninu igbo naa. Wọn kọọ si ara rẹ pe, "Asẹ ọkunrin ti nronu." Mo lọ sinu igbo naa diẹ, mo si tun pada wa sibẹ - mo si nṣe aṣaro lọkan mi wipe, "Aṣẹ ẹniti nronu, o nmu itọwọ amusiga jade." O dara, emi wà ni ipatẹ ọja agbaye ni ọdun diẹ sẹyin. Ranti pe wọn ni Yul Bryner ati awọn miran nibẹ. Wọ si nṣe ifiyeni pẹlu siga, bi wọn ti mu eefin siga ti wọn fi si ara ekute kan. Ni ọjọ meje si, ekute naa kun fun arun jẹjẹrẹ to bẹẹ ti ko lee dide.

Lẹyin naa, wọn fihan bi iyẹn ṣe maa nlọ sinu ẹdọ-foro eniyan. Awọn kan wipe, "Emi kii gbe eefin mi, mo ntu u jade ni ẹnu ni." Wọn fi han bi o ṣe npo mọ itọ ẹnu, ti o si ngbe itọ ati eefin mi. Ọkunrin naa wipe, "Ẹ ti gbọ ọpọ nkan nipa asẹ idi siga." O wipe, bi iwọ ba ni oungbẹ (O rii wipe o nii ṣe pẹlu oungbẹ) fun mimu siga, igi siga kan le tẹ oungbẹ yẹn lọrun fun igba diẹ. Ṣugbọn bi iwọ ba ti ni asẹ; iwọ yoo mu siga mẹrin ki o to ni itẹlọrun yẹn, nitoripe, iwọ nri idamẹrin eefin ti o wa ninu rẹ"

47 Wọn wipe, "Itọwo amusiga." Woo, iwọ ko lee ni eefin laiṣe wipe, o ni eedu, bi o ba si ti ni eedu, o ti ni jẹjẹrẹ. Ṣe o rii bẹyẹn. Ẹtan kan lasan ni.

Mo si ro nipa ile iṣẹ to nṣe siga kan ni orilẹ-ede yii, o si npawo nipa orilẹ-ede yii. Ti o si ni ẹtan bẹyẹn lati fi tan awọn eniyan Amẹrika - O tan wọn jẹ! Asẹ ẹniti nronu abi kin ni o sọ? Ẹtan lasan ni lati ta siga pupọ si. Nigba naa, mo ro nipa ọrọ yẹn, "Asẹ ẹnikan ti nronu". Mo ro o wipe, "Ero kan ti o dara niyẹn." Nitori naa, asẹ ẹniti nronu kan wa - iyẹn ni Bibeli. Ẹniti o ba ronu gidi yoo mu asẹ yii. Yoo si fun un ni itọwo ẹni olododo.

Bayi, iwo ko lee mu ẹṣẹ kọja ninu Bibeli yii. Rara, yoo da ẹṣẹ duro. O nfi asẹ rẹ sẹ ẹ kuro. Bayi, iwọ le lọ si ijọ rẹ, ki o si gba ohunkohun. Ṣugbọn iwọ ko lee la Bibeli yii kọja, ki o si ni ẹṣẹ. Ko ni ṣe e. O maa nsẹ gbogbo ẹṣẹ kuro. O si n fun eniyan ni asẹ ẹni mimọ. Nitori pe, bi ẹnikan ba ni ero lati jẹ Mimọ ki o si dabi Ọlọrun, ki o si jẹ ọmọkunrin tabi ọmọbinrin Ọlọrun, nigba naa, o nilo asẹ ti o tọ. Nitori naa, yoo da gbogbo ẹṣẹ duro si apakan ti ko wọ inu Bibeli, Ẹmi Mimọ nikan ni o si lee mu la Bibeli kọja, Ẹni ti o kọ Bibeli. Itọwo eniyan mimọ ni asẹ ẹniti nronu yẹn mu wa.

48 Bayi, a ri bi o ṣe kun fun itanjẹ loni. Ni. Matiu, 24:24 Jesu wipe, ni opin ọjọ, awọn ẹmi mejeeji yoo sunmọ ara wọn pẹkipẹki, to bẹẹ ti yoo tan ayanfẹ jẹ bi o ba ṣeeṣe. O ti sunmọ ara wọn to, iru ẹtan laarin otitọ ati eke ti a ni loni, titi de inu ijọba ati oṣelu. A ko tilẹ ni eniyan ti a lee fa kalẹ gẹgẹbi oloṣelu ti yoo duro fun otitọ ọkan rẹ patapata. Nibo ni awọn eniyan bi Patrick Henry, George Washington, ati Abraham Lincoln wa loni? Gẹgẹbi aarẹ wa ni Amẹrika ti sọ wipe, bi wọn ba nfẹ Ijọba ko-sọlọrun-ti-wọn-ni-ohun-gbogbo-sọkan, wọn lee ni in - ohunkohun ti awọn eniyan ba fẹ. Iyẹn jẹ ọrọ eniyan kan, ti ko lee sọ otitọ ọkan rẹ. O yẹ ki o jẹ eniyan kan ti o duro lori oṣuwọn ohun ti o gbagbọ. Ẹni yi kan ntẹ sibi ti ko ti si atako kankan ni.

Bi awọn eniyan si ti nṣe ninu Ijọ niyẹn. Wọn wa lati darapọ mọ Ijọ, wọn si wipe, "O dara, mo ti darapọ mọ ijọ bayi." Iwọ ngbiyanju lati tẹ oungbẹ mimọ yẹn lọrun ti Ọlọrun fi sinu rẹ, ti o ngbiyanju lati yi ọ pada si

ohun ti o dara. Iwọ si ngbiyanju lati tẹ ẹ lọrun pẹlu dídi ọmọ Ijọ, ati ṣiṣe atunwi ẹkọ adamọ kan, ati nkan bẹẹ, nigbati ko si ohun miran ti o le tan oungbẹ yẹn yatọ si iwalaaye Ọlọrun ti yoo kun ọ funra Rẹ.

49 Ẹkọ adamọ kan ko lee tẹẹ lọrun. Iwọ ko lee mu ki ẹkọ adamọ kan la Bibeli yii ja. Rara, titi mọ ohun ti wọn npe ni, “Ijẹwọ Igbagbọ awọn Aposteli,” Ko lee kọja ninu Bibeli yii. Fi ijẹwọ igbagbọ awọn aposteli“ han mi ninu Bibeli ti o wipe, ”Mo gbagbọ ninu Ijọ Katoliiki Mimọ ti Romu. Mo gbagbọ ninu Idapọ awọn eniyan mimọ“ nigbati Bibeli sọ wipe, alagbawi kanṣoṣo ni o wa laarin eniyan ati Ọlọrun, eyi si ni Jesu Kristi. Iwọ ko lee mu iyẹn la Bibeli kọja.

50 Iwọ ko lee mu awọn Ijó wọnyi, ṣòkòtò penpe, ati awọn nkan bẹẹ ti awọn eniyan nṣe loni, gbogbo ijó taka-n-sufe ati nkan bẹẹ la Ọrọ Ọlọrun kọja! Iwọ ko lee mu Ọlaju igbalode ọjọ oni kọja ninu Bibeli! O lodi sii.

Iwọ si ngbiyanju lati tẹ oungbẹ yẹn lọrun. Ṣugbọn, wo o, Bibeli yii yoo tán kiki oungbẹ ti ọkunrin ati obinrin olododo lọrun - Ẹmi Mimọ yii, ti wọn nfi rẹrin, ti wọn sọ pe, “Ori rẹ ti daru” Ṣugbọn iyẹn ni o ntẹ oungbẹ yẹn lọrun, ohun kan ti aye ko mọ nipa rẹ.

Wọn ti dibajẹ ara wọn kuro ni ibaptisimu Ẹmi Mimọ tootọ, ati Ọrọ Ọlọrun si kinni? Si koto ẹgbin ti ijọ, ti ẹkọkẹkọ ati adamọ ati idanimọ to lodi si ara wọn nipa ẹkọ Ijọ-to-fi-ẹkọkẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun. Bi o ba bere pe, “Kristẹni ni ọ bi?”

“Mẹtọdisti ni mi”

“Baptisti ni mi”

“Pirẹsibiteria ni mi”

Iyẹn ko ni itumọ kan si Ọlọrun. Iwọ ko lee mu awọn nkan yii la Bibeli kọja. Iwọ si ngbiyanju lati fi ohun miran tan Oungbẹ Mimọ ti Ọlọrun fi fun ọ lati Poungbẹ fun ara Rẹ. Ṣe bẹẹ ni?

51 Iwọ mọ pe, Dafidi sọ pe, Oun Poungbẹ fun “Ọlọrun alaaye.” Ni atetekọṣe ni Ọrọ wa, Ọrọ naa si wa pẹlu Ọlọrun. Ọlọrun si ni Ọrọ naa, Ọrọ naa si di ara, o n ba wa gbe. Nigba naa ko lee si itẹlọrun tootọ yatọ si Ọrọ yii, ti i ṣe Ọlọrun, ki O si di aaye ninu rẹ. Nigba naa, iwọ yoo ri Ọlọrun funra Rẹ, ti O nmu awọn ileri ti O ṣe ninu Bibeli ṣẹ.

52 Bayi, a ni orisirisi olutumọ Bibeli. Ijọ kan ntumọ rẹ ni ọna kan, omiran ntumọ rẹ si ọna miran. Awọn kan nmu ipa kekere ti wọn fẹ ninu rẹ, awọn kan mu ipa kan nibi ati nibo miran. Ṣugbọn, Ọlọrun ni Olutumọ Ọrọ Rẹ. Nigbati Ọlọrun ba ti ṣe ileri kan, ti O si mu Un ṣe, itumọ rẹ ni imuṣẹ naa. Bi mo ba ṣeleri pe emi yoo wa lalẹ yii, emi si niyii - imuṣẹ ileri mi niyẹn. Bi mo ba wipe, emi yoo pade rẹ ni owurọ, ti mo si wa nibẹ, ileri ti mo ṣe niyẹn. Ko nilo siṣe awawi kankan mọ. Mo nilati wa nibẹ. Nigbati Ọlọrun ba si ṣe ileri kan, ti O si wa, ti O mu un sẹ - itumọ ileri Rẹ niyẹn. Mo pe ẹnikẹni nija pe ki o gba Ọlọrun nipa Ọrọ Rẹ, ko si rii bi gbogbo Ọrọ Bibeli kii ba I ṣe otitọ. Bẹẹni!

Ohun ti oungbẹ yẹn jẹ niyẹn. Iwọ wipe, “Bi mo ba wa laye ni ọjọ Jesu ni, emi I ba ṣe eyi ati tọhun” Kin ni? Iwọ ngbe ni Ọjọ Rẹ bayi. Kin ni a nṣe nipa rẹ? Kin ni a nṣe? Kin ni o ti ṣe? Boya ohun ti awọn Farisi ṣe. Wọn jẹ ọmọ Ijọ, wọn si sẹ́ Jesu Kristi.

53 Awọn eniyan nsọ loni pe, “Awa nfi ẹsẹ Bibeli we ẹsẹ Bibeli, a nfi Iwe Mimọ we Iwe Mimọ” Iyẹn ki i ṣe otitọ. Wọn wipe, Ọrọ Giriki yii tumọ si eleyi, eyi si tumọ si Iyẹn“ Awọn Giriki funra wọn lati akoko Igbimọ Ijọ Nikia, ati awọn onkọwe nigba naa, wọn ni ariyanjiyan. Ọkan gba ohun kan ni ọna kan, onimọ ede Giriki miran si gba ohun miran, ọkan sọ pe, ohun ti o tumọ si niyi, omiran si wipe rara, ko tumọ si iyẹn. Wọn si ni ariyanjiyan lori ọrọ kan naa. A ko nilo itumọ ti awọn onimọ Giriki tabi ọrọ Giriki. Lati mọ Ọn ni Iye, lati mọ Ẹni naa Kristi funra Rẹ I ṣe, kii ṣe afiwe Ọrọ Bibeli.

Ifihan ni Ọlọrun kọ Ijọ Rẹ le lori. Bibeli wipe, “Abẹli, nipa igbagbọ…..” Igbagbọ si jẹ ifihan lati ọrun. Igbagbọ jẹ ifihan lati ọdọ Ọlọrun. O dara, a kọ́ gbogbo nkan wọnyi lori ifihan nigba naa. Bi a ko ba si fi nkan wọnyi han ọ…. Jesu wipe, “Mo dupẹ lọwọ Rẹ Baba, Iwọ ti fi nkan wọnyi pamọ fun awọn ọlọgbọn aye yii, iwọ si ti fi wọn han fun awọn ọmọ ọwọ ti wọn le kẹkọ” A kọ ohun gbogbo le ifihan. Iwọ nilati mọ Ẹni naa.

54 Iwọ ko si le tẹ iyẹn lọrun nipa didarapọ mọ Ijọ. O nilati wa Ọlọrun funra Rẹ ni awari, Oun si ni Ọrọ Rẹ ti O ti tumọ Ara Rẹ fun ọjọ oni: awọn ileri ti O ṣe fun ọjọ oni; awọn eniyan ti Oun yoo ni lọjọ oni. Ijọ ti ko ni abawọn tabi abuku, ti ko jasi Ijọ to fẹkọ-eniyan-lasan-dipo-Ọrọ Ọlọrun. Eyi tumọ si awọn eniyan naa, awọn aladori ẹnikan ti ko ni abawọn tabi abuku. “Ẹni meji yoo wa lori ibusun kan, Emi yoo mu ọkan, a o si fi ọkan silẹ; awọn meji yoo wa lori papa, Emi yoo mu ọkan, a o si fi ọkan silẹ”

Ṣugbọn nigbati oungbẹ mimọ lati dabi Ọlọrun yẹn ti o wa ninu rẹ. Ti iwọ si rii pe Ọrọ Rẹ wa ninu rẹ, ti o njẹri ara Rẹ, wipe, iwọ jẹ Iranṣẹ Ọlọrun. Ohunkohun ti Ọlọrun si sọ ni Iwọ nṣe. Nigba naa, iwọ ti nrin ni ọna ti

o tọ lati tẹ oungbẹ inu rẹ lọrun.

55 Nitootọ, awọn eniyan yoo fi ọ rẹrin ẹlẹya, wọn yoo sọ wipe, ori rẹ ti daru. Ṣugbọn ranti iru omi ti wọn nmu. Wo ibiti wọn wa. Njẹ o lee ronu nipa iṣẹlẹru kan to nfọn omi to mọ gaara jade kikankikan, ti ẹnikan si lọ duro sinu iho abata kan, ti awọn legbelegbe to ti ku wa ninu omi ti o nmu, pẹlu awọn ẹkọ adamọ gbogbo, ti o wa nfi ọ ṣe yẹyẹ? Kinla? ohun ko mọ nipa isun to ntan oungbẹ didara ti iwọ ngbe nipa rẹ. Bẹẹ ni o ri gẹlẹ.

A ni Ọlọrun alaaye, kii ṣe ẹnikan ti o ku ni ẹgbẹwa ọdun sẹyin, ti o si wa ninu iboji sibẹ. Ṣugbọn Ẹniti O jinde. {Heberu 13:8 wipe Oun jẹ ọkan naa lana, loni, ati titi lae}. Ẹmi Mimọ kan naa ti o sọkalẹ lọjọ Pẹntikọsti ni Ẹmi Mimọ kan naa ti o wa nibi bayi. Oun ni o ntẹnilọrun, nitoripe Oun ni Ọrọ naa. Bẹẹ ni. Ẹmi Mimọ ni O kọ Ọrọ naa. O tumọ Ọrọ naa. Bibeli sọ ninu Peteru keji pe, Ẹmi Mimọ ni O kọ Bibeli. Awọn eniyan ti Ẹmi Mimọ mi si ni o kọ Bibeli. Bayi iwọ ko lee ṣe. Iwọ ko lee tan Oungbẹ mimọ yẹn pẹlu ohun miran bikoṣe Ọlọrun Funra Rẹ, ti O ngbe inu rẹ gẹgẹbi Ẹmi Mimọ. Imọ iwe, Igbe aye ẹya rẹ, didarapọ mọ Ijọ kan, kika ẹkọ adamọ lati ori, jijẹ ara ẹgbẹ ijọsin kan, gbogbo iwọnyi ni o dara. Ṣugbọn wọn ko le tẹ oungbẹ mimọ yẹn lọrun.

56 Mo feti si Billy Graham, Ajihinrere nla yẹn ni alẹ ijelo. Mo sọ fun yin, emi ngbadura fun Un bayi ju ti tẹlẹ lọ, nigbati mo ri bi o ti ba awọn eniyan wi, fun ohun ti wọn ṣe. O wipe, ẹgbẹ awọn oniwaasu yẹn nlọ loju titi, pẹlu kọla ọrun wọn ti wọn de sẹyin, wọn lọ sibi ti ko yẹ ki wọn lọ, wọn lọ yọju si ohun ti ko kan wọn. Ṣugbọn, awọn oniwaasu yẹn nlọ loju titi, wọn npatẹwọ, wọn si njin ẹsẹ mọlẹ. Wọn dabi gbarayilẹ ẹlẹsin aimọ kan. Bayi, ṣe o rii, ṣugbọn wọn ni ohun kan to nmu inu wọn dun. Obinrin kan lọ ki ori rẹ bọ ohun kan nibẹ yẹn, wọn si ro wipe ajẹriku kan ni. Obinrin naa ko ni idi fun ohun ti o ṣe.

Bayi, a rii wipe awọn ọkunrin wọnyi ni ohun kan ti wọn le e patẹwọ nipa rẹ. Inu wọn dun. Wọn nṣe ohun kan. Bi iwọ ba le ṣe iyẹn fun ilana kan ti iwọ gbagbọ pe o tọ nibẹ yẹn; bi iwọ ba si wa nile isin, ti ẹnikan patẹwọ, to fi ẹsẹ lu ilu, awọn diakoni yoo mu un jade kuro nile isin. Wo o, wọn ti sọ awọn eniyan wọn di koto ẹgbin ti ẹkọ adamọ ijọ ẹlẹsin lasan, dipo ki wọn bọ́ wọn pẹlu Ọrọ Mimọ Ọlọrun to ni Ibukun, ti a fi agbara ajinde Jesu Kristi waasu rẹ.

57 Wo o, wọn gbiyanju lati tan oungbẹ wọn nipa sisọ pe, “Emi ni ọmọwe Lagbaja” tabi ki wọn sọ ile iwe ẹsin ti wọn ti jade wa. Ṣugbọn iyẹn ko ni itumọ kan. Ṣugbọn wọn gbiyanju lati tẹ ara wọn lọrun wipe, “Bayi, Ọlọrun yoo gba mi wọle nitoripe mo jẹ Oluṣọ-aguntan Rẹ. Ọlọrun yoo gba mi wọle nitori pe emi ni Fada mimọ, Tamẹdu, tabi Bisọbu Doola, tabi ohun kan bẹyẹn” Wọn ngbiyanju lati tẹ oungbẹ wọn lọrun nipa iyẹn nigbati ko ṣeeṣe. “Mo ni Ph.D. LLD. Mo ni oye ile ẹkọ Yunifasiti. Iyẹn dara, ṣugbọn ni ti emi, o tumọ si bi iwọ ṣe jina si Ọlọrun to. Bẹẹ ni; Iwọ tun njina si Ọlọrun si, bi o ti nni oye wọnyẹn.

Nipa iriri nikan ni o fi le mọ Ọlọrun. Iwọ ko lee fi Iwe Kikọ mọ ọn; a o tun ọ bi sinu Rẹ ni. O jẹ ohun kan ti Ọlọrun nfun ọ. Iwe kikọ ko ni ohun kan I ṣe pẹlu rẹ. Ọkan ninu awọn eniyan to ga julọ ninu Bibeli ko tilẹ lee kọ orukọ ara rẹ. Peteru mimọ. Oun ati Johanu; otitọ niyẹn. Bibeli wipe awọn mejeji jẹ ope ati alaimọkan eniyan. Ṣugbọn o wu Jesu lati fun un ni kọkọrọ Ijọba naa, nitoripe o poungbẹ fun Ọlọrun. Amin! Oungbẹ fun Ọlọrun. Idapọ, bẹẹ ni sa!

58 Mo ro nipa Aisaya, ọdọkunrin daradara yẹn. O wa ninu tẹmpili ni ọjọ kan. O ti tẹjumọ ọba Israẹli, ti o jẹ eniyan nla kan lọjọ naa. Ọba yii jẹ ẹniti awọn obi rẹ tọ dagba ni ọna Ọlọrun. Nigbati o si bẹrẹ, Ijọba rẹ ati oṣelu rẹ mọ́, o si ṣe ifẹ Ọlọrun. Aisaya si wo o, o ro wipe o jẹ eniyan nla kan; o si fi ṣe awokọṣe. Ṣugbọn, Iwọ ko gbọdọ fi ẹnkẹni ṣe awokọṣe bikoṣe Jesu Kristi. Gbogbo eniyan ni yoo ṣubu. Nigba ti o ṣe diẹ si, Ọba naa gbiyanju lati gba ojuṣe alufaa ṣe ninu tẹmpili. A si fi ẹtẹ kọlu u.

Nigba naa, Aisaya ni iporuru ọkan. Nitori naa, o lọ sinu tẹmpili, o si bẹrẹ si gbadura. O ro wipe, oun nilati lọ gbadura fun igba diẹ. Si woo, Wolii ni Aisaya. O n kepe Ọlọrun ni ọjọ kan, o si ri Iran kan. O si ri awọn angẹli, awọn Kerubu ti wọn fi iyẹ bo oju wọn, ẹsẹ wọn, wọn si n fi iyẹ apa meji fo. Wọn si nlọ siwaju ati si ẹyin, si oke ati ilẹ ninu Tẹmpili, wọn nkigbe wipe, “Mimọ Mimọ, Mimọ, ni Oluwa Ọlọrun Olodumare.”

59 Aisaya si ni oungbẹ nla si Ọlọrun. O ṣeeṣe ki a ti ran an lọ sile iwe. O ni ero nla nipa ohun ti Ọlọrun nilati jẹ, o ti fetisi awọn alufaa. O ti wa ninu tẹmpili. A ti kọ ọ lati jẹ onigbagbọ. Ṣugbọn oun ko tii ri I lojukoroju ri. O ni ifẹ lati ṣe ohun ti o dara. O fẹ tọ́, ṣugbọn oun sa ni kiki ẹkọ lasan nipa rẹ. O ni ẹkọ ẹsin eniyan nikan.

Ṣugbọn nigbati o de inu tẹmpili lọjọ yẹn, ti o ri awọn Kerubu wọnyẹn ti wọn nfo kiri, o si rii wipe, awọn angẹli wọnyi nsiṣẹ isin niwaju Ọlọrun, wọn ko si mọ ohun ti ẹṣẹ jẹ. Fun wọn lati duro niwaju Ọlọrun, wọn nilati bo oju wọn mimọ, lati lee duro niwaju Ọlọrun. Nigban naa ni wolii yẹn kigbe wipe, “Egbe ni fun mi, nitori mo jẹ eniyan alaimọ ete. Gbogbo ẹkọ ẹsin mi ti mo ti kọ, sibẹ, emi jẹ alaimọ ete, mo si ngbe pẹlu awọn alaimọ-ete.

Gbogbo ẹkọ wọn nipa ofin Ọlọrun ti wọn ti ṣe, ko ti I de ibiti o wa niwaju Ọlọrun bayi, o si ri Ọlọrun pẹlu oju rẹ, o si ri igunwa Rẹ ninu tẹmpili nigbati O joko ninu Ọrun loke. Aisaya niyii, ni ojukoroju pẹlu otitọ. O si

kigbe wipe, “Ègbé ni fun mi, nitori mo jẹ ẹni alaimọ ete. Gbogbo imọ ẹkọ ẹsin ti mo ti kọ nipa Ọlọrun, mo ti wa ni ojurinju pẹlu otitọ bayi. Mo jẹ alaimọ ete, ti o ngbe pẹlu awọn eniyan alaimọ ete.

Gbogbo ẹkọ wọn nipa ofin ati ohun gbogbo ti wọn ti ṣe, ko sunmọ tosi ohun ti o ri, nigbati o de iwaju Ọlọrun, ti o si ri Ọlọrun pẹlu oju rẹ, o ri i wipe, isẹti aṣọ igunwa Rẹ kun inu tẹmpili nigbati Oun joko si ibi giga ni Ọrun. O wa nibẹ pẹlu arigbamu ni ojukoroju. O si kigbe wipe, “Mo jẹ alaimọ ete, mo si ngbe laarin awọn eniyan alaimọ ete”

60 Nigba naa ni Kerubu kan fi ẹmu mu ẹyinna kan lati ori pẹpẹ, o si fi kan awọn ete aimọ naa, o si yi i pada kuro ni ojo tabi onimọ ọpọlọ lasan, olukọni kan lasan si wolii Ọlọrun, ti Ọrọ Ọlọrun le gba ẹnu rẹ jade. Dajudaju, nigbati o wa niwaju Ọlọrun, ohun gbogbo yatọ. Oungbẹ, ti o ti ni yẹn de ipo kan, to bẹẹ ti a kun Un.

Jẹ ki nsọ fun ọ, ọrẹ, emi ko bikita fun oye Ijọ ti iwọ darapọ mọ, tabi Iwe Ijọ ti o kọ orukọ si, ọna ti iwọ gba, yala a bu omi wọn ọ, tabi a ri ọ bọmi, tabi ohun miran. Afi igbati iwọ ba pade Ẹni naa, Jesu Kristi, Oun kanṣoṣo ti yoo tẹ ọ lọrun niyẹn. Isọyigi-ara ko lee ṣe. Iwọ le fo soke-sodo, ki o kigbe to bi o ṣe fẹ. Tabi ki o sare kaakiri, iwọ si le fi ede miran sọrọ to bi o ṣe fẹ. Awọn nkan mimọ, ti o si dara niwọnyi. Emi ko lee sọrọ lodi si wọn. Ṣugbọn o di igbati iwọ ba pade Ẹni naa, ti O fun ọ ni itẹlọrun yẹn, ohun kan ti o kun gbogbo iṣan ara rẹ, kii ṣe nipa isọyigi ara, ṣugbọn nipa itẹlọrun ti Ọlọrun nfun ni.

61 Mo ti maa nri ami kekere kan, ti o wipe, “Bi oungbẹ ba ngbẹ ọ, sọ wipe, ”Pafee“ Iyẹn ni ohun mimu kan nigbati mo wa ni ọmọde. Mo ranti ọjọ kan ti mo nbọ lati odo ẹja pipa - mo lọ pẹja nibi adagun odo kan ti ko ṣe e mu - oungbẹ si ti gbẹ mi de oju iku. Mo si ri ami naa ti o wipe, ”Bi oungbẹ ba ngbẹ ọ, saa sọ wipe, “Pafee”.

Mo si bẹrẹ si sọ wipe “Pafee, Pafee” Oungbẹ tun bọ ngbẹmi si de ipo ti ko si itọ lẹnu mi mọ. Ṣe o rii, iyẹn ko lee ṣe.

Ko si ohun ti yoo tan oungbẹ naa. Emi ko bikita. Iwọ le mu ẹlẹrindodo-kooki, ohunkohun ti o lee mu ninu awọn ẹlẹrindodo yẹn. Ko si ohun ti yoo tan oungbẹ ti ara bii omi odo ti nṣan to si tutu. Iyẹn ni yoo mu oungbẹ ara kuro. Gbogbo ohun ti o ku wọnyi saa jẹ alupayida omi.

62 Ki si ni idi ti awa yoo fi gba paṣipaarọ kan nigbati ojulowo ibaptisimu Ẹmi Mimọ wa, ti o ma a ntẹ gbogbo ọkan eniyan lọrun! Nigba naa, iwọ yoo duro ṣan an niwaju iku. Gẹgẹbi aposteli nla naa Paulu ti wipe, “Iwọ iku, oró rẹ da? Iwọ isa oku, iṣẹgun rẹ da? Ṣugbọn ọpẹ ni fun Ọlọrun, ẹniti o fun wa ni Iṣẹgun nipasẹ Jesu Kristi. Iriri naa niyẹn, arakunrin! Iyẹn ni o ntẹ oungbẹ inu rẹ yẹn lọrun. Iwọ ko nilati ṣe ohun miran nipa rẹ. Bẹẹ ni, o nfọ ete eniyan mọ.

Awọn eniyan kan si wa, ti wọn ngbe nipa isọ-yigi-ara. Awọn kan wipe “Awa ni ọpọlọpọ iyẹn ninu awa Pẹntikọsita.” Wọn si wipe, awọn yoo wọle. O dara. Wọn yoo patẹwọ, wọn yoo lo ohun elo orin. Bi ilu ati orin bati dakẹ, ohun gbogbo yoo duro bii igbati a da omi nla pa ina isọji naa. A si ti ni iwa lati maa ṣe iyẹn. O ti di àṣà fun wa.

63 Jẹ ki n sọ ohun kan fun ọ. Nigbati iwọ ba n sin Ọlọrun ni ẹmi ati ni otitọ - nigbati o ba ti da àṣà lasan fun ọ, nitori ti o jẹ ojuṣe, nitori o ro wipe, bi iwọ ko ba pariwo, tabi fo soke-sodo tabi jo si orin naa, ẹniti o wa nitosi rẹ yoo ro wipe o ti pada sẹyin - iwọ nmu omi lati inu omi odo ti ko san, ti o si kun fun ẹgbin ati oorun. Bẹẹ ni. A fi igbati Ẹmi Mimọ funra Rẹ ba kun gbogbo ọkan rẹ, isan ara rẹ, ti o si nru jade ninu rẹ, nigba naa, yala awọn ohun elo orin ndun tabi ko dun, tabi a nkọ “N o sunmọ Ọ, Ọlọrun mi,” tabi ohun ti o le jẹ, ti Ẹmi Mimọ si n lu agogo ninu ọkan rẹ! Iyẹn nfun eniyan ni itẹlọrun! Iyẹn ni Ipin Ọlọrun to ntẹni-lọrun. Ohunkohun ti o yatọ si iyẹn, iwọ ko mọ si.

Iwọ lee fi ede titun sọrọ ti eniyan ati ti angẹli, iwọ le fi gbogbo ohun ini rẹ bọ awọn talaka, iwọ le sọtẹlẹ, iwọ si le ni imọ ki o ni oye gbogbo ijinlẹ - sibẹ, ki o ma jẹ nkankan. (Korinti kinni 13) Titi ti ohun kan ti o le tẹ ọ lọrun. “Ọkan mi npoungbẹ fun Ọlọrun alaaye, gẹgẹ bi agbọnrin ti n mi hẹlẹ si ipado omi. Bi emi ko ba ri Ọ, emi yoo ku.” Nigbati iwọ ba nwa Ọlọrun ni ọna yẹn, ohun kan yoo ṣẹlẹ. Ẹmi Mimọ ni yoo mu ọ lọ si orisun nla Ọlọrun yẹn. Bẹẹ ni sa!

64 Bayi, ohun ti o dara ni lati jọsin ninu ẹmi, otitọ ni. Ṣugbọn nigba miran iwọ ni ẹmi laisi otitọ. Ihinrere Johanu ori kẹrin wipe, “A nsin Ọlọrun ni ẹmi ati ni otitọ. Jesu si ni Otitọ. Bẹẹ ni o ri gẹlẹ. Oun si ni Ọrọ naa.

Awọn ìṣàn ti Ọlọrun ran si ọ lati tẹ ọ lọrun nipa ti ara, Satani ti dibajẹ gbogbo wọn. O ti fi majele sinu olukuluku wọn. Otitọ niyẹn.

O ti mu ìṣàn nla ti Ijọ naa. Iyẹn ni ọna Ọlọrun. Jesu wipe, “Lori apata yii, ni Emi yoo kọ Ijọ Mi le; ẹnu ọna isa oku ki yoo si bori rẹ” Ariyanjiyan si wa nipa iyẹn. Ijọ Katoliiki ti Romu wipe, O kọ sori Peteru. Bi o ba ri bẹẹ, Peteru pada sẹyin pẹlu itiju. Nitori naa, a ko kọ sori Peteru, tii ṣe okuta kekere kan.

Awọn to tako Ijọ Aguda si wipe, O kọ ọ sori ara Rẹ, Jesu Kristi. Kii ṣe wipe, emi fẹ yatọ, ṣugbọn mo tako iyẹn. Oun ko kọ Ijọ le ori eyikeyi ninu awọn mejeji. O kọ ọ lori ifihan ẹniti Oun I ṣe. O wipe, Alabukun fun ni iwọ Simoni ọmọ Jona. Ẹran ara ati ẹjẹ kọ ni o fi eyi han ọ, ṣugbọn Baba Mi ti nbẹ ni Ọrun ni o fihan fun ọ" Kii ṣe nipa imọ - iwọ ko kọ ọ ninu iwe kankan, iwọ ko kọọ nipa jijẹ ọmọ Ijọ kan, iwọ ko kọ ọ nipa pipa ariwo kan. Ṣugbọn Ẹmi Mimọ funra Rẹ ni o fi ẹniti Jesu I ṣe han ọ. Ati lori apata yii ni Emi yoo kọ Ijọ Mi, ẹnu ibode Isa oku ki yoo bori rẹ. A ti tẹ oungbẹ Mimọ yẹn lọrun ninu Jesu Kristi. Ohun niyẹn. Ohun ti a nilati wa niyẹn. Tẹ oungbẹ naa lọrun pẹlu Iyẹn. O dara.

65 Ìmọ̀? Áh, àh. Imọ jẹ ohun ti o tobi. Ni ọjọ oni, a kun fun imọ pupọ. Gẹgẹbi mo ti nsọrọ nijelo, mo sọrọ nipa imọ. Ọkunrin kan duro ni ita, o si nba ọrẹ mi kan sọrọ ti o duro nibẹ. O wipe, "Bi ọkunrin yii ko ba gbagbọ ninu imọ, kin ni idi ti o fi nka Bibeli?"

Nigba naa, mo ro o wipe, "Bi ohun ti Jesu Oluwa sọ ko ba ye wọn, bawo ni ohun ti alaigbọn bi temi sọ yoo ṣe ye wọn?" Ọrọ Jesu gan ko tilẹ ye wọn, bi O ti sọ ọ yekeyeke to. O sọ lọjọ kan pe, "Laiṣe pe iwọ jẹ ara, ki o si mu ẹjẹ Ọmọ eniyan, iwọ ko ni Iye ninu rẹ" Oun ko ṣalaye rẹ. O kuro nibẹ. Otitọ ni.

Wọn wipe, "Ajẹniyan ni Ọkunrin yii. O ni ki a jẹ ẹran ara Oun, ki a si mu ẹjẹ Oun. Amujẹ-eniyan ni. O si fẹ ki a di ajẹniyan ati amujẹ-eniyan" Awọn onimọ ọpọlọ! Ṣugbọn O wipe, "Awọn aguntan Mi ngbọ ohùn Mi. Ọrọ Rẹ yoo lọ sọdọ awọn ayanfẹ ti Ọlọrun ti yan nipa imọtẹlẹ Rẹ. Ko si ẹniti o le tọ Mi wa, laiṣe wipe Baba Mi ba faa. Gbogbo awọn ti Baba si ti fi fun Mi, yoo tọ Mi wa. Yoo ye wọn." Ko ye awọn ọmọ ẹyin yẹn. Ṣugbọn wọn gba A gbọ. Otitọ niyẹn. Ọpọlọpọ nkan ni ko ye mi, ṣugbọn mo gbagbọ sibẹ. Nitoripe Ọlọrun sọ bẹẹ, bẹẹ ni.

66 Imọ - njẹ o mọ wipe satani ni o ni ihinrere imọ? Njẹ iwọ mọ? O waasu rẹ ninu ọgba Edẹni si Efa, ṣugbọn a tan obinrin naa nipa ihinrere imọ rẹ. Bayi, satani ti dibajẹ gbogbo eniyan pẹlu imọ. Otitọ niyẹn gẹlẹ. Wọn mu awọn eto ẹkọ iwe, wọn fi sinu Ijọ. O dara ni ile iwe, ṣugbọn kii ṣe ninu Ọrọ Ọlọrun. Rara sa. Iwọ ko le mọ Ọlọrun nipa imọ iwe. Iwọ ko lee mọ Ọlọrun nipa mimọ iṣiro ati nipa sisọ ọrọ nla-nla.

Paulu jẹ ọmọwe. Ṣugbọn nigba ti o wa sọdọ Kristi, ti o si gba Ẹmi Mimọ, o sọ fun Ijọ kọrinti pe, "Emi ko tọ yin wa pẹlu awọn ọrọ ẹtan didun nipa ọgbọn eniyan, (bi o tilẹ jẹ wipe, o lagbara lati ṣe bẹẹ), ṣugbọn, mo wa nipa agbara ati ifihan-fayeri Ẹmi Mimọ, ki igbagbọ yin le wa ninu Ọlọrun, ki o ma si wa ninu ọgbọn eniyan kan".

Bayi, nigba miran, a maa nṣe awọn eto ijọ. Wọn a si maa yan oluṣọ-aguntan wọn. Ijọ yoo yan Oluṣọ-aguntan rẹ. Wọn yoo wipe, "Oluṣọ-aguntan yii ni oye Iwe akanpọ meji lati ile iwe giga. O kọ nipa iwa eniyan fun ọdun mẹrin. O si kọ ẹkọ eyi, iyẹn, ati tọhun" Wọn yoo si fi ibo yan ọkunrin naa sipo. Tori kin ni? Dipo ki wọn yan oluṣọ-aguntan kan ti o gba Ọrọ Ọlọrun gbọ wipe o ni imisi Ọlọrun, ti yoo si waasu ọrọ naa laibikita ohun ti ẹnikẹni sọ nipa rẹ.

67 Ọlọrun sọ fun Ezekieli pe, 'Waasu Iyẹn, yala wọn gba a gbọ, tabi bẹẹkọ. Iwọ waasu rẹ lọnakọna." Bẹẹni. Yala wọn gba a, tabi wọn ko gba a, iyẹn ko ṣe Pataki. Wọn ko gba Jesu, ṣugbọn O lọ taara, O waasu sibẹ. Dipo Oluṣọ-aguntan tootọ ti yoo waasu Ọrọ naa, ti yoo gba Ọlọrun gbọ, wọn gbiyanju lati mu onimọ ọpọlọ lasan, ọkunrin ti o mọ Iwe julọ. Ọkunrin ti yoo waasu iṣẹju marundogun fun wọn, ki wọn le tete de ile lati lọ ṣe nkan miran. Ki Ricky le mu ibọn rẹ, ki o si jade lọ. Ki wọn le lọ si awọn ijó 'taka-n-sufe' wọn ati ohun gbogbo bẹẹ. Kii ṣe ohun kan bi ko ṣe idibajẹ ti adalu nipa imọ iwe. Otitọ niyẹn. Ohun ti o jẹ gan niyẹn. Bẹẹni.

Ṣugbọn, kin ni gan? O tẹ ifẹ wọn lọrun. O tẹ ifẹ ọkan ọmọ Ijọ to nifẹ aye lọrun. Ko tẹ ifẹ ọkan eniyan mimọ lọrun. Eniyan Mimọ yoo gba Ọrọ naa ni gbogbo igba. Ṣugbọn, wọn wipe, "Ah, awọn eniyan yẹn ti yi lori diẹ. Wọn ko mọ ohun to dara. Wọn ngbiyanju lati gbe ni akoko to ti kọja lọ".

68 Njẹ ko sajeji? Mo jade wa si Iwọ oorun nibi, mo si ri wipe wọn ngbiyanju lati gbe nigba to ti kọja. Wọn maa nfẹ igba ọjọ agẹsin-daran to ti kọja lọ. Wọn fẹ lọ si Kentucky, wọn fẹ ṣe bi igba atijọ yẹn. Wọn fẹ huwa bẹẹ, wọn si ṣe awọn eto rẹ. Ṣugbọn nigbati o ba di ti Igbagbọ-atijọ, wọn ko fẹ iyẹn rara. Akoko atijọ? Mo wa sibi ni akoko ipatẹ ọja maluu. Mo ri i pe, wọn ni obinrin kan to tobi nibẹ, ọda alawọ ewe wa ni oju rẹ, o ge irun mọlẹ, o fi siga si ẹnu rẹ. Kinla, bi wọn ba rí ohun kan bi iyẹn nigba atijọ, wọn yoo ro wipe, aisan kan ni o ba awọ ara rẹ jẹ. Wọn iba si fi si àhámọ́. Bi o ba ṣe wipe iya rẹ jade pẹlu iru aṣọ ti iwọ ati ọmọ rẹ nwọ loni? Kin ni I ba ṣẹlẹ? Wọn I ba ti mu un lọ si ile itọju arun ọpọlọ. Dajudaju. O jade sita lai wọ aṣọ sikẹti rẹ.

Ranti bayi, ohun kan naa ni loni. Eniyan ti ńrà ninu ara rẹ. Wọn ti n de opin ibimọ ni ẹni ogun ọdun si ọdun marun-dọgbọn, ẹya ọpọlọ wọn ti ra pẹlu. Awọn eniyan ko ni oye mọ. Wọn ko mọ ohun ti ọmọluwabi tumọ si. Wọn ko mọ iyatọ laarin rere ati buburu.

Bi o ba si wo eto ẹkọ wọn…….

69 Njẹ iwọ mọ wipe, imọ iwe (Mo si le fi da ọ loju) jẹ ti eṣu? Kii ṣe mimọ-ọn-kọ mọ-ọn-ka ni mo nsọ,

ṣugbọn mo nsọ nipa fifi ìmọ̀ iwe sinu Ijọ. Kin ni ilana ise-jọba nini-ohun-gbogbo-sọkan duro le lori? Imọ Ijinlẹ ati imọ iwe. Iyẹn ni Ọlọrun wọn, tii ṣe satani. Ohun ti o fihan Efa niyẹn. Ohun ti wọn si di mu niyẹn sibẹ. Nisisiyi, o ti de inu awọn Ijọ wa. O ti de inu Ijọ Baptisti, Mẹtọdisti, ati Pirẹsibiteria, Pẹntikọsita ati gbogbo wọn. Imọ iwe, imọ ọpọlọ, awọn eto nla-nla, ti o mu ki eniyan jinna si Ọlọrun si. O kuna. Bẹẹni, sa.

Bayi, a rii wipe, o tẹ ifẹ ọkan wọn lọrun. Nigbati Ijọ ba dibo yan ohun bi iyẹn ni ọna yẹn, o fihan ohun ti o wa ninu ọkan awọn eniyan Ijọ naa, ohun ti ifẹ ọkan wọn jẹ, ati ohun ti wọn n poungbẹ fun. Wọn fẹ sọ wipe, "Oluṣọ-aguntan wa nimọ pupọ. Ko tilẹ kọ̀ bi awọn ọkunrin ba lọ wẹ pẹlu awọn obinrin, o tilẹ ba wa lọ paapaa.

70 Ọmọbinrin kekere kan sọ fun ọmọ mi Sera ni ijelo, Oluṣọ-aguntan rẹ ti lọ si Afirika. Nigbati o si pada de, ọmọbinrin naa bọ aṣọ rẹ kuro lalẹ ọjọ yẹn, o si ku awọtẹlẹ penpe si idi rẹ, o si jo ijó wàtúsì lati da baba rẹ lara ya, nitori ti ọkunrin naa ti lọ si Afirika; Watusi jẹ ẹya kan ni Afirika. Ah, iwọ jẹ ki n gbọ pe ọmọbinrin kan ni ijọ mi gbiyanju lati ṣe iyẹn! Watusi! Wo o, o fihan bi wọn ṣe ri.

Oluṣọ-aguntan kan yoo si joko, yoo wo ọmọ ijọ rẹ ti o jẹ ọmọbinrin ọmọ ọdun mẹrindinlogun si mejidinlogun ti o bọ ara si ihoho bẹyẹn lati jo niwaju rẹ, ki o si lọ bẹẹ? Iyẹn fihan wipe, oun funra rẹ wa lati inu koto-ẹgbin. Iranṣẹ Ọlọrun yoo ṣe ohun kan bi Iyẹn! Dajudaju. Iyẹn dabi ọrọ ti o le leti, ṣugbọn mo ri I wipe mo nwaasu si ọpọlọpọ kaakiri orilẹ ede yii lọwọ. Ṣugbọn, mọ eleyi pẹlu, arakunrin ati arabinrin jẹ ki nsọ fun ọ, otitọ niyẹn.

71 Ẹyẹ Igun a maa wa oku ẹran. Otitọ niyẹn. Iyẹn si ti ku! Otitọ niyẹn gẹlẹ. Iyẹn fihan gbangba, ohun ti o wa ninu ọkan wọn, ohun ti o nṣe ifẹ ọkan bẹẹ ninu wọn. Ọkan wọn nifẹ nkan bẹyẹn. Ọkan wọn nfẹ Ijọ onimọ ọpọlọ lasan to ga loju eniyan, nibiti awọn eniyan ti wọṣọ daradara, ti oluṣọ-aguntan si lo iṣẹju marundogun si ogun iṣẹju lati waasu, bi o ba si lo kọja iyẹn, wọn yoo jẹ ki Igbimọ Diakoni Ijọ baa sọrọ, oun ko si gbọdọ sọrọ lodi si ẹṣẹ, ko gbọdọ sọ ohun kan nipa wiwọ ṣokoto penpe, tabi sọrọ lodi si ikuna awọn eniyan, ko gbọdọ sọ iyẹn rara. Bi o ba ṣe bẹẹ, Igbimọ Ijọ yoo yọ ọ danu kia. Ṣe o ri ohun ti o jẹ? Asẹ́ ironu tiwọn niyẹn.

Bibeli sọ ni Johanu kinni 2:15, "Bi iwọ ba nifẹ aye, tabi awọn nkan aye yii, ifẹ Ọlọrun ko si ninu rẹ".

72 Bayi, gbogbo ariwo asan ti wọn nṣe loni gẹgẹbi Ijọ nkọ? Wọn nkọ ijó-aye ninu Ijọ - apejẹ bonko, bingo, awọn apejẹ ifẹ aye, ijó tàka-n-súfe fun awọn ọdọ ninu Ijọ ati gbogbo nkan wọnyi. Wo Elvis Presley, eṣu kan to duro bi eniyan. Pat Boone, Ricky Nelson, awọn ifasẹyin to buru julọ ti Orilẹ-ede tii ni ri. Otitọ niyẹn.

Wọn wipe, "Ah, wọn nifẹ ẹsin. Wọn nkọrin Kristẹni." Ko yẹ ki Ijọ gba Iyẹn laaye. Awọn olorin yii nlọ sile ijó, ile ibajẹ, ile ẹṣẹ, wọn yoo ṣere, wọn yoo jo pẹlu ifẹkufẹ gbogbo. Ni alẹ ọjọ keji, wọn yoo wa sibi pẹpẹ, wọn yoo si sọkun. Ni alẹ ọjọ to tẹle, wọn yoo kọ orin niwaju Ijọ. Áh, àh! Bawo ni ibajẹ yoo ti lọ jinna lati gbilẹ to? Bẹẹni, Sa! Jẹ ki o kọkọ fi daniloju pe o jẹ eniyan Ọlọrun. Kii ṣe gbogbo nkan ti wọn nṣe wọnyi, nitoripe oun ti le ta gìtá tabi nkan bẹẹ.

Nipa Ifẹ ọkan rẹ, iwọ lee sọ ẹniti o wa ni ipo adari ninu ọkan rẹ. Nipa ohun ti o nifẹ, iwọ le mọ ẹmi to nsakoso rẹ. Iwọ wipe, "Emi ro pe awọn nkan yẹn ko buru, Arakunrin Branham" Iwọ sa ti ranti pe, ohun ti ọkan rẹ poungbẹ fun, ti o si nfẹ lati tẹlọrun, bi ki i ba ti i ṣe Ọrọ yii, nigba naa, o kuna. Nitoripe, Ẹmi Mimọ ngbe nipa Ọrọ naa nikan.

73 Mo fẹ ki o ri ewu nla miran, ki a to pari. Bi iwọ ko ba jẹbi eyikeji ninu awọn nkan ti mo ti darukọ wọnyi. Ewu miran ni didagunla si oungbẹ. Iwọ wipe, "Emi ni oungbẹ mimọ, ṣugbọn emi ko jẹbi, Arakunrin Branham nipa dida ara pọ mọ Ijọ, ati nkan bẹẹ." Wo o, lati kuna fifun oungbẹ ni omi ati ounjẹ, iwọ yoo ku. Bi iwọ ba si dagunla si oungbẹ fun Ọlọrun ninu rẹ, iwọ yoo ku nipa ti ẹmi.

Ẹ n pe fun isọji. Iwọ nduro de ki Ijọ rẹ ni Isọji. Iyẹn kii ṣe isọji fun ọ. Isọji naa yẹ ki o bẹrẹ ninu rẹ, nigbati iwọ ba bẹrẹ si poungbẹ fun Ọlọrun. O lee ma si ọmọ Ijọ rẹ miran to nwa isọji. Bi o ba bẹrẹ ninu rẹ, yoo kan awọn miran.

Ṣugbọn, bi o ba dagunla si oungbẹ yẹn, o lewu. Bi iwọ ba kọ lati fun wara maluu nigbati ọmu rẹ kun fun wara, maluu naa ko ni ni wara mọ. Otitọ niyẹn gẹlẹ. Bi iwọ ba kọ lati mu omi nigbati oungbẹ ngbẹ ọ, ti o wipe, "Emi ko ni mu omi mọ" Iwọ yoo ku. Bi o ba kọ lati jẹun, iwọ yoo ku. Nitori naa bi Iwọ ba kọ lati fun Ẹmi Mimọ ni Ọrọ Ọlọrun, Iwọ yoo ku.

74 Ẹyin Kristẹni, ẹyin Baptisti, Pirẹsibiteria, Pẹntikọsita, Assemblies ti Ọlọrun, Oneness, twoness, Mẹtalọkan, ohunkohun ti iwọ le jẹ - ko ṣe Pataki si mi. Emi ko ro pe o ṣe Pataki si Ọlọrun.

Aladori ẹnikan ni iwọ. Ẹnikan ni ọ. Iwọ ko lee lọ sọrun gẹgẹbi ijọ kan, tabi ijọ ẹlẹkọ adamọ kan. Iwọ yoo lọ sọrun ni iwọ nikan, o wa laarin iwọ ati Ọlọrun. O pari. Ko ṣe Pataki Ijọ ti o wu ki iwọ lọ. Bi iwọ ba si kọ lati ka Bibeli, ati lati gba Bibeli gbọ ati Ẹmi Mimọ lati jẹ ounjẹ yẹn, Iwọ yoo ku. Jesu sọ ni Ihinrere ti Johannu 4:3 wipe, eniyan ki yoo wa nipa akara nikan, ṣugbọn nipa gbogbo Ọrọ, kii ṣe diẹ ninu rẹ. Bi a ba mu diẹ nihin, diẹ

lọhun. Mo pe Iyẹn ni arin-rinajo to ntọrọ ọkọ wọ ti Bibeli.“ Wọn wipe, ”O dara, mo gba eyi gbọ, ṣugbọn jẹ ki a lọ si ibi yii“ O nilati mu gbogbo Ọrọ naa lẹṣẹẹṣẹ.

Jesu wipe, “Eniyan yoo wa laaye nipa gbogbo Ọrọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade” Ṣe iwọ mọ iyẹn?

Iwọ si mọ pe, a ti ṣe ọjọ ti a ngbe ninu rẹ yii ni ọjọ idibajẹ ti ẹsin.

75 Ọmọbinrin mi pe mi ni ijelo, o wipe, “Dadi, ẹ wa sibi (o npe mi lati apa kan ninu ile si apa miran ninu ile) ẹ wa gbọ eto isin orin kan. O jẹ orin kikọ. Ricky kekere kan si nkọrin nibẹ. Bi mo ba ti i ri ohun kan to tabuku fun ohun mimọ kan ri, eto yẹn ni. Awọn eniyan yẹn, wọn ṣe e bi ere itage ti aye. Wọn jẹ ẹya India, wọn si nṣe bi ọmọ ita, wọn fo soke, wọn ngba ara wọn ni ẹ́ṣẹ́.

Tori kin ni, ki lo ṣẹlẹ si otitọ ọkan? Awọn orin mimọ atijọ yẹn da, ti a maa nkọ pẹlu ayọ ninu Ẹmi Ọlọrun, ti omije si maa nda loju wa? Nisisiyi, a ngbiyanju lati sé èémí titi di igbati ko si èémí mọ ninu wa titi ti oju wa yoo yi awọ pada lati fihan pe a jẹ akọrin. A ti gba apẹẹrẹ iyẹn lati ere itage Hollywood, ati gbogbo awọn eto ti a nri wọnyi, nipa orin ọpọlọ lasan ati yiyi ohun pada. Mo nifẹ orin to dara. Mo fẹ maa gbọ awọn orin mimọ atijọ, ti a kọ pẹlu ọkan otitọ ati ẹmi Pẹntikọsti. Ṣugbọn, mo korira didun bi ẹyẹ ti wọn npe ni orin loni. Bẹẹ ni. Mo ro pe ohun to buru pupọ julọ ni. Idibajẹ ni. Otitọ niyẹn.

76 Mo fẹ ri ọkunrin ti o jẹ ọkunrin gidi. Mo korira lati ri eyiti o nwọ awọtẹlẹ Iyawo rẹ kiri, ti o si ṣe irun were si ori. Emi ko lee pe iyẹn ni ọkunrin. Oun ko mọ boya ọkunrin ni oun, tabi obinrin. Otitọ niyẹn. Ṣe ẹ ri bi obinrin ti nge irun rẹ lati dabi ọkunrin, ti ọkunrin si n ṣe irun rẹ bii ti obinrin. Ọkunrin nwọ awọtẹlẹ Iyawo rẹ; obinrin si nwọ ṣokoto ti ọkọ rẹ. Idibajẹ alupayida ni gbogbo rẹ.

Ohun kan naa ni o ti ṣẹlẹ si awọn orilẹ-ede, awọn eniyan, awọn Ijọ pẹlu ohun gbogbo. Iwọ Ọlọrun, opin nkan wọnyi da? Ipadabọ Jesu Kristi Oluwa ni opin gbogbo rẹ.

77 Nitori naa, bi iwọ ko ba fi Ọrọ Ọlọrun bọ Ẹmi Mimọ, iwọ yoo ku. Jesu wipe, gbogbo Ọrọ nilati jade nipa Ẹmi Mimọ. Fetisilẹ bayi, bi iwọ ba gbiyanju lati fi ohun miran bọ ọ, bi o ba jẹ ojulowo Ẹmi Mimọ ni o wa ninu rẹ, O mọ iyatọ. Ranti bayi pe, Ọrọ Ọlọrun ni ounjẹ Ẹmi Mimọ. Kii jẹ isọyigi ara; kii jẹ ẹkọ iwe. Kii jẹ lilọ sile isin; kii jẹ awọn imọ ẹsin.

Iyatọ nla ni o wa laarin Otitọ Ọrọ naa ti a misi, pẹlu imọ ẹsin nipa ọgbọn eniyan. Gbogbo awọn onimọ ẹsin ni akoko ti Jesu wa laye, wọn mọ gbogbo ọrọ naa lẹ́sẹ-ẹsẹ, lati oju iwe kinni de ipari. Wọn si ti kọ ọ́ silẹ bi Meseya ṣe nilati wa. Ohun to ṣẹlẹ niyẹn. Gbogbo wọn si ṣì í. O mọ ohun ti Jesu sọ nigbati o de? O wipe, “Ti baba yin eṣu ni ẹyin i se. Iṣẹ rẹ ni ẹyin yoo si ṣe pẹlu” A ko fihan fun wọn ohun ti Ọrọ tootọ jẹ. Wọn ṣi awọn igun kekeke yẹn bi wọn ṣe nṣi i loni.

Wọn wipe, “Bi iwọ ba jẹ ẹgbẹ Ijọ yii…”

“Ti iwọ si darapọ mọ eleyi.” Ma gba iyẹn gbọ. Iwọ nilati jẹ ti Kristi.

Bi ohun kan ba si wa ninu rẹ, to npoungbẹ fun Kristi…..

78 Saa ranti, nigbati iwọ wa ni iha baba rẹ, iwọ wa ninu Rẹ nigba naa. Ṣugbọn baba rẹ ko mọ ọ nigba yẹn, iwọ ko si mọ baba rẹ. A si nilati bi ọ. Ọlọrun la ọna nipasẹ iya rẹ ti o jẹ ilẹ fun iru naa. Lẹyin naa, iwọ wa, o si di ọkunrin, tabi obinrin. Nigba naa, iwọ mọ baba rẹ, baba rẹ si lee ni Idapọ pẹlu rẹ.

Ranti bayi, bi iwọ ba ni iye ainipẹkun, iye rẹ wa ninu Ọlọrun lati ibẹrẹ. Iye naa wa ninu Ọlọrun tii ṣe Ọrọ naa. Lẹyin naa, Ọrọ naa di ara, Jesu Kristi, ti iṣe Ọlọrun ti O wa gbe ninu ara ti Rẹ̀ (o sọ ara Rẹ di Ọmọ Ọlọrun). Nigbati Ọlọrun wa gbe ninu Rẹ, iwọ wa ninu Rẹ, nigbati a kan mọ agbelebu, iwọ wa ninu Rẹ. A kan ọ mọ agbelebu pẹlu Rẹ, iwọ ku pẹlu Rẹ ni Kalfari. A sin ọ pẹlu Rẹ sinu oke yẹn, iwọ si jinde pẹlu Rẹ ni ọjọ ajinde, Bayi, iwọ njoko pẹlu Rẹ ninu awọn Ọrun ninu Rẹ. Bayi, iwọ ni idapọ pẹlu Rẹ. Ọlọrun funra Rẹ di ọkan ninu wa. Ko si ẹniti o ti ri Baba nigba kan ri. Ọmọ bibi kanṣoṣo Rẹ ni o ti fihan-fayeri. Ọlọrun di eniyan ki o ba le ni Idapọ pẹlu rẹ gẹgẹbi eniyan. Bayi, Oun jẹ ẹlẹran ara, gẹgẹbi iwọ.

Ọlọrun di eniyan laarin wa gẹgẹbi Jesu Kristi Ọmọ Rẹ. Ninu Rẹ ni Ọlọrun wa. Ọlọrun ni Oun, ko din, ko yatọ si Ọlọrun. Ọlọrun ni. Ọlọrun farahan-fayeri ninu ọmọ naa Jesu Kristi, ti o sọ ọ di Emmanuẹli, gẹgẹbi wolii ti sọ.

79 Bayi, nigba naa, ki a to fi ipilẹ aye lelẹ, a ti kọ orukọ rẹ sinu Iwe Iye ti Ọdọ-aguntan naa. Nigba naa, kinni iwọ lee jẹ? Ẹmi Mimọ njẹ Ọrọ Ọlọrun. Bayi, ninu Iwe Ifihan 22:19, Bibeli wipe “Ẹnikẹni ti o ba mu ọrọ kan kuro ninu eleyi, tabi fi ọrọ kan kun un, a mu ipa rẹ kuro ninu Iwe Iye” Wo bi o ti jinlẹ to?

Ẹmi Mimọ ko lee gbe nipa nkan ti aye - gẹgẹbi ẹyẹ adaba ati igun. Igun jẹ alagabagebe nla kan. Ẹniti o jẹ igun, lee jade lọ sori papa, ki o si jẹ alaikama fun ọjọ kan, ki o si tun fo lọ sori oku ẹran, ki o jẹ ẹ. Ṣugbọn

adaba pẹlu le jẹ alikaama ni gbogbo ọjọ, ṣugbọn oun ko lee jẹ oku ẹran, nitoripe, adaba ni. Adaba ko si ni oronro. Bi o ba jẹ oku ẹran yẹn, yoo pa a. Ko ni oronro. Bi o si ti ri niyẹn - ko ni inu kikoro.

Bẹẹ ni o si ri pẹlu ojulowo Kristẹni. Wọn ko fẹ ohun ti aye yii. Wọn sa njẹ Ọrọ Ọlọrun nikan - ohun mimọ, aṣẹ ẹniti nronu. Wọn ngba inu iyẹn nikan kọja. Awọn nkan oku aye nrun si wọn. Wo igun naa nigba ikun omi, o fo lati ori oku ẹran kan de omiran, o njẹ awọn oku ẹran yẹn. Oun ko pada wa sinu ọkọ. Ṣugbọn adaba yẹn ko ri ibi isimi fun ẹsẹ rẹ. O pada wa sinu ọkọ, nibiti o ti nri alikama jẹ. Bi a ti nṣe niyẹn. A ngbe nipa Ọrọ Ọlọrun.

80 Ni Psaamu 42, o nilati jẹ pe Dafidi kọ Psaamu yii nigbati o jẹ Isansa, ti o wipe, “Ọkan mi npoungbẹ fun ọ bi agbọnrin ti npoungbẹ fun omi ipado” Wo o. Dafidi jẹ isansa. A ti tami ororo lee lori. O mọ pe oun yoo di Ọba. Wolii naa ti tami ororo lee lati di Ọba. Kiyesi bayi, oun si niyẹn. O ni ẹgbẹ ọmọ-ogun ti wọn jẹ iran alaikọla. O wa lori oke nibiti awọn Filistini ti pagbo yi ilu rẹ to fẹran ka, nitori ẹsẹ wọn. O si nilati jẹ ọjọ kan ti ooru gbona, ti Dafidi kọ Psaamu naa, “Bi agbọnrin ti nmi hẹlẹ si ipado omi.

Kiyesii, Dafidi ni ipo yii, o wo isalẹ. O wo ilu rẹ ti o fẹran, o si ranti igbati o wa ni ọmọde, o ma a nko awọn aguntan jade lọ nibi adagun omi yii. O jẹ ilu ti o ni omi, o si jẹ ilu alikama. Nitootọ, Bethlẹhẹmu tumọ si ile ounjẹ Ọlọrun. Nigbati Dafidi si ranti bi o ti maa nlọ sibẹ ti yoo si mu omi tutu, to si dara yẹn; oun si niyi, ti o duro nibi gẹgẹbi Isansa, ti ko wa pẹlu awọn eniyan rẹ. Ko ni ibiti o le lọ. Ọkan rẹ ti nilati poungbẹ fun omi to dara to si tutu yẹn.

81 O ni awọn iranṣẹ kan ti ifẹ ọkan rẹ to kere ju lasan si jẹ aṣẹ fun wọn. Awọn mẹta si ba ọta ja fun ibusọ maili marundogun lati la aarin ọta kọja titi ti wọn fi bu omi pada wa fun Dafidi lati mu.

Ṣugbọn, oun wa ni oke yẹn, o ṣeeṣe ki o sa mu ohunkohun ti o ba ri, lati inu igo ti a fi awọ ewurẹ ṣe, ti o si ti gbona ni ọjọ to gbona yii. O ro o wipe, “Bi emi ba sa lee pa oungbẹ yii. Bi mo ba le de kanga ti o wa ni Bethlehemu, ki n dubulẹ si isun omi yẹn, ki n si mu.”

82 Nigbati, awọn mẹta yii si lọ, ti wọn bu omi naa pada wa, oungbẹ ọkan rẹ ga ju ti omi yẹn lọ - kii ṣe fun Bethlehemu, ṣugbọn fun Jerusalẹmu. O fi omi naa rubọ, o wipe, “Emi ko ni mu omi yii” O si daa silẹ. Ọkan rẹ poungbẹ to ga julọ fun Ọlọrun, ju oungbẹ ara rẹ lọ. O daa silẹ, o poungbẹ fun ile Ọlọrun, fun omi to ntẹ ọkan lọrun ti o wa lati Jerusalemu ti oke.

Jesu sọ ni Johanu 6:33, “Emi ni ounjẹ Iye. Emi ni akara Iye” Bẹthlẹhẹmu tii ṣe ile Ọlọrun, ijọ wa, Ijọ Ọlọrun ti aye yii - a nifẹ lati lọ sile isin laye yii. Ṣugbọn Jerusalẹmu ti Ọrun ga pupọ ju ti aye lọ, tii ṣe Ọlọrun. Oungbẹ ti ọkan lati wa pẹlu Rẹ ga pupọ ju lati ni itẹlọrun wipe o dara pọ mọ ijọ nibikan. Wo o, didi ọmọ ijọ kan ko lee tan oungbẹ yẹn. Dafidi fidi rẹ mulẹ nibi yii. Omi ti o ti ile Ọlọrun wa, o daa silẹ lati wa ojurere lati lee gba omi tutu to dara lọdọ Ọlọrun. Oungbẹ fun Iye Ọlọrun ga ju oungbẹ ara lọ.

83 Kiyesi Jerusalẹmu. Jerusalẹmu wa lati oke; Bibeli wipe, ohun ni Iya gbogbo wa. Kristi si ni Iya wa, a mọ iyẹn. Ọlọrun ni Iya wa, nitori a bi wa nipa Rẹ. Ọrọ naa tumọ si alaafia. Jerusalẹmu, Ṣalọmu, tii ṣe alaafia. Jeru-ṣalọmu, o tumọ si alaafia. Oungbẹ ti ọkan fun Omi Iye nilati ju oungbẹ lati jẹ ọmọ Ijọ lọ. A ko lee tán oungbẹ ti ọkan - oungbẹ tootọ na. A lee dibajẹ rẹ nipa alupayida. Iwọ le ro pe Iwọ ti dara to, nigbati o ba darapọ mọ Ijọ. Ṣugbọn ko ri bẹẹ. Iyẹn ko lee tẹ oungbẹ tootọ fun Ọlọrun lọrun. Ko lee ṣee. Ko ṣeeṣe.

84 Dafidi wipe, (Psaamu 42:7) “Ibu omi npe Ibu omi, nipa hiho siṣan rẹ” Ipe ọkan ni. Woo, mo ti ma a nfi eyi ṣe apejuwe. Bi ìpẹ́pẹ́ ba wa ni ara ẹja, o nilati wa nibẹ fun un lati luwẹ. O nilo iyẹn. Bi o ba wa sọ wipe, “Emi yoo jẹ ẹja to yatọ. Emi yoo jẹ ẹja to jafafa, ti o si jẹ ọmọwe. Emi yoo gba ẹkọ ẹsin kan gbọ. Mo gba wipe, emi ko nilo ipẹpẹ yẹn. Oun ko ni rin jinna ninu omi yẹn, abi? Otitọ si niyẹn.

Ki a gba pe, igi kan wipe, “Bayii, mo mọ wipe ori ilẹ ni o yẹ ki emi hu si. Bẹẹ ni. O yẹ ki n hu sori ilẹ. Ṣugbọn emi yoo jẹ igi kan ti o yatọ. Mo fẹ ki a gbe mi si aarin titi, ki a ba a le ri mi daradara.” Igi naa ko ni wa laye pẹ. Otitọ niyẹn. Nigbati ibu omi ba pe ibu omi. O kọja jijẹ ọmọ ijọ. O kọja bibọ ọwọ oniwaasu. O si ju gbigbe igbe-aye daradara to rin san an. O nilo ohun kan lati tẹ ọ lọrun. Ó sì ń dà lati ọdọ Ọlọrun sinu ọkan rẹ. Ibu omi npe ibu omi, nipa ariwo hiho sisan rẹ, Oluwa, ibu omi npe ibu omi.

85 Iru oungbẹ wo ni a ro pe o wa ninu wa lalẹ yii? Awa gẹgẹbi awọn eniyan Pẹntikọsita, nibo ni a de? Iru oungbẹ wo ni o wa ninu wa? Iru oungbẹ wo ni o wa ninu mi? Iru oungbẹ wo ni o wa ninu rẹ? Maṣe gbiyanju lati pa oungbẹ mimọ fun Ọlọrun yẹn.

Ni ọpọ ọdun sẹyin, nigbati wọn ni wura lori awọn oke wọnyi, mo ka itan kan nipa rẹ. O si ti duro si ọkan mi. O sọ wipe, awakusa kan lọ si awọn oke yii, o si nwa wura. O si ri ibiti wura pọ si. O si npada lọ pẹlu ero yii wipe, nigbati ohun ba de inu Ilu nla pada, oun yoo di ọlọrọ, iṣoro ohun si ti tan. O si wipe, “Ni ọla, emi yoo de inu ilu, o pari” O ku irinajo ọjọ kan ti yoo fi pada de ilu; oun si ni apo nla kan ti o kun fun wura.

86 O ni aja kan pẹlu rẹ - emi ko fi aja ṣe akawe Ẹmi Mimọ bayi, ṣugbọn mo fẹ fi ṣe alaye ni. Ni gbogbo oru naa, awakusa yii dubulẹ lori ibusun rẹ. O si nronu pe, “Ni ọla, emi yoo ko gbogbo wura yii wọle, emi yoo si di ohun ti mo ti nfẹ. Mo ti maa nfẹ lati di ọkunrin ọlọrọ. Mo fẹ ni awọn ohun to dara” Nigba naa ni aja rẹ bẹrẹ si gbo, nitoripe awọn ọta rẹ nbọ nitosi. O si jade lọ sita, o wipe, “Panu mọ!” Aja naa si dakẹ. Ko si pẹ ti o dubulẹ pada, ti o fẹ sun, aja yii tun gbo, o nfo soke pẹlu ẹwọn ọrun rẹ. Ọkunrin yii tun lọ sibi ilẹkun o wipe, “Panu mọ! Mo fẹ ki o mọ wipe, ni ọla, emi yoo di olowo.” Iyẹn si ni àlá ńlá rẹ.

Ṣugbọn aja tun ngbo lẹẹkan si.

87 Nigbẹyin, agara da ọkunrin naa, o jade lọ pẹlu ibọn rẹ, o si pa aja naa. O wipe, “Emi ko kuku nilo rẹ mọ. Ni ọla, emi yoo di olowo” O si gbe ibọn si igun kan, o kọ ẹyin si ilẹkun, o si sunlọ. Ọkunrin kan si ti ntẹle e fun ọpọ ọjọ; o yọ wọle, o si paa. Ko si di olowo. Ṣe o rii. O pa ohùn ikilọ to nkilọ fun un pe, ewu wa nitosi.

88 Arakunrin, arabinrin, maṣe gbiyanju lati pa ohun ikilọ yẹn, tii ṣe ipe mimọ ninu ọkan rẹ fun Ọlọrun. Maṣe paa nipa didarapọ mọ ijọ, nipa kika akọsori kan; tabi jijẹ ọmọ ẹgbẹ ẹlẹsin kan. Ohun kanṣoṣo ni o lee tẹẹ lọrun. Iyẹn ni Ẹni naa, Jesu Kristi.

Bi agbọnrin ti nmi hẹlẹ si ipado omi, bẹẹni ọkan mi n poungbẹ fun ọ, Ọlọrun. Ọkan mi n poungbẹ fun Ọlọrun alaaye.“ Ohun kan wa ninu rẹ ti o fẹ ri iṣẹ Ọlọrun. Ọkan rẹ poungbẹ fun un. Maṣe ni ohun to yatọ si iyẹn. Ma jẹ ki Oluṣọ-aguntan kan sọ fun ọ pe, ki o sa ti bọ ọwọ, tabi darapọ mọ Ijọ, tabi ki o jẹ ara ẹgbẹ ẹlẹsin kan. Maṣe pa ipe mimọ yẹn lẹnumọ. O nkilọ kun ọ. Ọjọ kan nbọ ti iwọ yoo de opin aye rẹ.

89 O dabi obinrin kekere kan ninu ilu ti a ti wa. Ọmọbinrin kekere kan lọ sile isin nibẹ, o si jẹ ọmọbinrin to dara. Oun si ma a nwa loju popo ilu. O ni irun gigun, ti o si di sẹyin. Oun ko si fi ọda kun ara rẹ. Obinrin yii ma a nfi ṣe yẹyẹ. O wipe, “Bi kii ba ṣe oniwaasu olori pẹlẹbẹ ti iwọ ni nibẹ yẹn (o nsọ iyẹn nipa mi) iwọ iba jọ eniyan gidi. Ṣugbọn iwọ ri bi ohun atijọ kan to ti tẹ.” O saa sọrọ pupọ si ọmọbinrin to dara yii, ni gbogbo igba ti o ba rii. O wipe, “Oluṣọ-aguntan tiwa jẹ ọlaju, kin ni o ṣe ọ ti iwọ fi nṣe bẹyẹn? Bi a ṣe wọṣọ ko ṣe pataki, ati awọn ohun ọṣọ ara ti a lo.” O ṣe pataki! Bibeli Ọlọrun sọ pe o ṣe pataki. A o gbe nipa gbogbo Ọrọ Ọlọrun. Ọmọbinrin kekere yii, ko kọbi ara si ọrọ rẹ. O tẹsiwaju. Akiri-waasu ni bayi.

90 Ọdọbinrin gbajumọ yẹn si ni aisan ibalopọ kan, o si ku. Ọrẹ mi kan ni o fi oogun sinu rẹ ti nmu oku gan. Nigbati o nku lọ, nigbati o ku tan, ọkunrin naa ngbọ oorun kan. Obinrin naa ni iho ni ẹgbẹ rẹ - aisan gbajumọ nipa ibalopọ. Awọn obi rẹ gan ko si mọ ohun ti o ṣe e. O si ku. Ṣugbọn ki o to ku, o nkọni nile ẹkọ ọjọ isinmi. Gbogbo awọn ọmọ kilasi rẹ si wọle wa. Wọn fẹ ri I ngbati o ba nlọ si ọrun, ti awọn angẹli si ngbe lọ. Oluṣọ-aguntan rẹ si wa nita ti o nmu siga, bi o ti nrin soke sodo. Gbogbo wọn si fẹ kọrin nigbati o ba nlọ. Wọn mọ wipe yoo ku. Awọn dokita sọ wipe o ti nku lọ. Nitori naa, gbogbo wọn fẹ ri bi awọn angẹli yoo ṣe gbe e lọ.

91 Ni ojiji, nigbati o dojukọ okodoro iku. Oun ti jẹ olotitọ si ijọ rẹ. O si jẹ olukọ ile ẹkọ ọjọ isinmi, ati ọmọ ijọ to ṣe daradara ninu ijọ ẹlẹkọ adamọ nla naa. Nigbati o bẹrẹ si ja pitipiti, iku kọ lu u. Oju rẹ si yọ sita, o si wipe, “Mo ti ṣegbe!” O wipe, “Mo ti ṣegbe, ẹ ba mi pe Oluṣọ-aguntan yẹn wa.”

Oluṣọ-aguntan rẹ si pana siga rẹ, o wọle wa, o si wipe, “Wo o, a o jẹ ki dokita fun un ni abẹrẹ ki o le sun.”

Obinrin naa wipe, “Emi ko fẹ abẹrẹ-orun! Iwọ ẹlẹtan eniyan yii! Emi nku bayii, mo si nlọ sinu ọrun apaadi. Mo si ṣegbe nitoriti iwọ kuna lati kọ mi ni otitọ. Lọ ba mi pe ọmọbinrin Goodhue yẹn, si tete mu un wa sibi. Oun ni o tọ.”

Iwọ duro titi iwọ yoo fi dojukọ otitọ. Maṣe gbiyanju lati da ikilọ mimọ yẹn lẹkun. Maṣe pa a pẹlu ibọn ti ọgbọn iwe igbalode. Fetisilẹ si ikilọ Ẹmi Mimọ yẹn lalẹ yii to nkilọ fun ọ. “Emi ni ọna, otitọ, ati iye. Ko si ẹnikẹni ti o le wa sọdọ Baba bikoṣe nipasẹ Mi. Oun si ni Ọrọ naa.

Jẹ ki a tẹriba fun iṣẹju kan.

92 Mo fẹ tun Ọrọ Jesu Oluwa kan sọ si, nigbati iwọ nro nipa rẹ. Jesu sọ ni Matiu 5 pe, “Alubukun fun ni awọn ti ebi npa, ti oungbẹ ngbẹ.” Ibukun tilẹ ni lati ni oungbẹ yẹn ninu rẹ.

Se iwọ ti de ipo kan, ti gbogbo inu rẹ ti kun fun idibajẹ nipa ẹkọ ijọ to fẹkọ-kẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun ati ẹgbẹ aladamọ kan, ilana ijọ kan, didarapọ mọ ẹgbẹ ẹlẹya kan? Ṣe eṣu ti fun ọ ni omi idọtin yẹn mu, ti iwọ si n mu un bi ẹlẹdẹ ninu ẹrẹ, nigbati iwọ ko tilẹ mọ omi ojulowo to ntan oungbẹ fun Ọlọrun lati ri arigbamu rẹ to ngbe ninu rẹ?

Bi iwọ ba ri bẹẹ lalẹ yii, bi iwọ ba si ni oungbẹ fun Ọlọrun, jẹ ki nsọ fun ọ pe.

Isun kan wa to kun fẹjẹ

To tiha Jesu yọ

Ẹlẹṣẹ mookun ninu rẹ

O bọ lọwọ ẹbi

Ole ni lor'agbelubu

Yọ lati ri isun na

Nibẹ mo le wẹ eeri mi

Ati ẹṣẹ mi nu

Gba ti mo figbagbọ risun naa

Ti nṣan fun ẹjẹ Rẹ

Irapada d'orin fun mi

Ti n o maa kọ titi

93 Bi iwọ ba ti ni oungbẹ yẹn lalẹ yii, lati mọ nipa Ọlọrun si ati lati sunmọ Ọn, ṣe iwọ yoo na ọwọ rẹ soke bayi nigbati a tẹri gbogbo ba; wipe "Gbadura fun mi" Iwọ Ọlọrun, wo awọn ọwọ naa. Ni gbogbo ibiti ọrọ yii njade lọ, lati ila oorun, ariwa, iwọ oorun ati guusu - ẹyin to wa ninu iyara - ẹ nawọ yin soke si awọn Oluṣọ-aguntan to wa nibẹ. Ohunkohun ti iwọ si nfẹ, ohun kan n poungbẹ fun Ọlọrun ninu rẹ. Oungbẹ mimọ yẹn, ma ṣe tẹ ẹ lọrun pẹlu ohun miran.

Iwọ wipe, "Ah, Arakunrin Branham, mo ti pariwo nigba kan, mo ti jo ninu Ẹmi"

Maṣe gba iyẹn, rara. Duro titi ti itẹlọrun yẹn yoo fi de, Ipa itẹlọrun ti ẹkunrẹrẹ Ẹmi Mimọ ki o kun ọ. Nigba naa, agogo ayọ ti pipariwo, fifi ede sọrọ, ati jijo ninu ẹmi yoo wa. Iwọ ko ni ṣe e nipasẹ ohun elo orin. Iwọ yoo ṣe e, bi iwọ ba n lọ loju titi, ninu ọkọ ayọkẹlẹ rẹ. Iwọ yoo ṣe nigbati o ba ngbalẹ ile rẹ. Iwọ yoo ṣe e nigbati o ba nkan iso sinu ogiri nibi isẹ gbẹna-gbẹna rẹ. Nibikibi ti o ba wa, ayọ ti ko ṣe fẹnu sọ yẹn to si kun fun ogo….. Bayi, ẹ jẹ ki a gbadura.

94 Baba wa Ọrun, iwaasu yii lalẹ yii, ti o gun, ti a pẹ lori rẹ. Ṣugbọn Ọlọrun ọwọn, jẹ ki Ẹmi Mimọ Rẹ fi itumọ rẹ si ọkan kọọkan. Ninu Ijọ yii lalẹ yii, ọpọ ọwọ ni a na soke ni gbogbo ile isin yii, ati nibi gbogbo. A gbadura fun wọn Ọlọrun Ọwọn. Jẹ ki ipa ti Itẹnilọrun ti Ọlọrun yẹn, tii ṣe Kristi, Ireti Ogo, Ireti Iye ninu Rẹ, jẹ ki o tọ olukuluku lọ ni gbogbo orilẹ-ede; lati California lọ si New York, nibiti wọn ti wa ni owurọ (wọn n fetisilẹ nibẹ) ni New Hampshire, titi lọ si Boston, ati lọ si Texas, Indiana, Carlifornia, nibi gbogbo.

Ọlọrun wo awọn ọwọ yẹn. Wo ohun to wa labẹ ọwọ naa, Oluwa, ọkan ti ebi npa, ti oungbẹ ngbẹ naa.

95 Ọjọ alupayida yii, nibiti eṣu ti fọ awọn eniyan loju, lati sa darapọ mọ Ijọ, ki wọn si ro pe o ti to. Wọn si le wo ara wọn, ti wọn ri ohun ti wọn nṣe, ati ifẹ ọkan wọn lati dabi aye; nigbati Bibeli sọ pe, bi a ba nifẹ aye, ifẹ Ọlọrun ko si ninu wa.

Sa ro o, Baba, bi eṣu ṣe le e dibajẹ Ọrọ Otitọ yẹn; bi wọn ṣe le sọ wipe, "Ah, a gba Bibeli gbọ, ṣugbọn kii ṣe eleyi. A ko gba eleyi gbọ. A gbọ wipe, Iran miran ni eyi wa fun. A gba wipe eyi ni iyẹn"

Nitoripe Ijọ kan to fẹkọ-kẹkọ-rọpo-Ọrọ-Ọlọrun ti yi ọkan wọn po sinu koto ẹgbin yẹn, nigbati Jesu wipe "Ẹnikẹni to ba mu ọrọ kan kuro ninu eleyi, tabi fi ọrọ kan kun un, a o mu ipa tirẹ kuro ninu iwe iye".

Ọlọrun ọwọn, ro nipa awọn ijakulẹ nibi idajọ, nigba ti awọn eniyan ba gbe igbe aye to dara, iwa mimọ, ti wọn lọ sile isin pẹlu gbogbo otitọ inu - ti wọn si ṣegbe.

96 Ro nipa awọn Farisi yẹn, bi wọn ti kọ wọn lati ọmọ kekere ninu ọrọ naa, wọn dagba nipa awọn ile iwe lati mọ ohun gbogbo. Wọn jẹ mimọ - wọn nilati mọ, tabi ki wọn sọ wọn lokuta pa. Jesu si wipe "Ti eṣu Baba yin ni ẹyin ise"

Bi Israẹli ti lọ si Egipti {si jẹ ki eyi jẹ ikilọ fun awọn Pẹntikọsita}, bi Mose, wolii kan ti wa si Egipti lati mu Ọrọ Ọlọrun ṣẹ, lati mu imọlẹ irọlẹ wa fun wọn; bi wọn ti ri awọn iṣẹ Iyanu Ọlọrun; bi wọn ti tẹle e, la okun pupa ja, ti a baptisti wọn si Mose, wọn si lọ sinu aginju, wọn jẹ ounjẹ angẹli to da lati ọrun - lẹyin naa, wọn kọ lati gba gbogbo Ọrọ naa gbọ. Nigbati wọn pada de Kadesi-barnia lati ilẹ ileri, wọn wipe, "Omiran ni wọn. Awa ko le e ṣe e", nigbati Ọlọrun wipe, "Mo ti fun yin ni ilẹ naa".

Awọn onigbagbọ to de aala, ti Jesu wipe, "Gbogbo wọn ni o ṣegbe" Wọn ti ku, wọn ṣegbe laisi Ọlọrun,

bi wọn tilẹ ti ṣe gbogbo nkan wọnyi. Wọn ri awọn iṣẹ iyanu wọnyẹn, wọn gbadun, wọn jo soke-sodo leti okun pẹlu Miriamu, nigbati wọn lu ṣẹkẹrẹ. Ẹni mẹta pere lati inu miliọnu meji ni o wọle.

97 A mọ eyi Baba, pe nigbati àtọ̀, awọn iru ọmọ lati ara akọ ati abo ba wa papọ, ẹyọ kan ninu milọnu ni o ngba a. Iru iye kan lati ara ọkunrin lo npade ẹyin kan lara obinrin. Miliọnu kan ti o ku yoo si ṣegbe. Miliọnu meji lo jade lati Egipti. Meji, Joshua ati Kalebu lo wọ ilẹ ileri, o jasi ẹyọ kan ninu miliọnu kan.

Baba, mo wariri, nigbati mo ro iyẹn. Ro ni gbogbo aye loni, ẹẹdẹgbẹta miliọnu Kristẹni ni o wa, iyẹn yoo jẹ ẹẹdẹgbẹta eniyan bi O ba de lalẹ yii. Ọlọrun, jẹ ki a ranti pe gbogbo Ọrọ Ọlọrun ni o duro fun iranti mani-gbagbe. A nilati gba a gbọ, a nilati gbọran sii. Nigbati Iwọ si wipe, “Ronupiwada, olukuluku yin ki a si baptisti yin ni orukọ Jesu Kristi fun Imukuro ẹṣẹ yin, ẹyin yoo si gba ẹbun Ẹmi Mimọ. Nitori ileri naa wa fun yin, ati awọn ọmọ yin, ati awọn to wa lọna jijin rere, iye awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yoo pe.”

Ọlọrun, Iwọ si n pe lalẹ yii. Ileri naa wa niwọn igba ti Iwọ ba npe. Awọn oniwaasu ti yi awọn eniyan ni ọkan po, wọn si ti dari wọn nipa ile iwe ẹkọ ẹsin ti wọn sọ wipe, “Ah, ṣa a ti Gbagbo,” Eṣu pẹlu gbagbọ. Ṣugbọn ko lee gba Ẹmi Mimọ. Judasi Iskariotu ṣe gbogbo ohun ti awọn ọmọ ẹyin ti o ku ṣe, o waasu ihinrere. Ṣugbọn nigbati o ku ki o gba Ẹmi Mimọ, o fi ara rẹ han.

Ọlọrun, jẹ ki awọn eniyan ilẹ naa mọ lalẹ yii wipe, laisi iriri Ẹmi Mimọ, wọn yoo ṣegbe. Jẹ ki o jẹ alẹ yii, ni ọkan wọn yoo ri ipin itẹlọrun, Oluwa, a fi wọn le Ọ lọwọ. Tirẹ niwọn Oluwa. Awa ni ojuṣe lati waasu Ọrọ naa. Mo gbadura pe ki wọn gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan wọn, ki a si kun wọn pẹlu Ẹmi Mimọ. A beere ni Orukọ Jesu. Amin.

Mo fẹran, Jesu yii

Tori O kọ fẹ mi

O san gbese igbala mi

Ni Kalfari

98 Ah, ṣe Oun jẹ ipin itẹlọrun rẹ? Ah, ah. Ṣe o fẹran Rẹ pẹlu gbogbo ọkan rẹ? Bayi, awọn Ọrọ naa, a ma a ge eniyan nigba miran. Ṣugbọn sa jẹ ki a kọrin ninu Ẹmi, bayi, olukuluku wa. Jẹ ki a bọwọ́ pẹlu arakunrin ti o joko lẹgbẹ rẹ tabi arabinrin, ki o si wipe, “Ki Ọlọrun bukun ọ atipo” bi a ṣe nkọ orin naa lẹẹkansi.

Mo fẹran, Jesu yii

Tori Ọ kọ fẹ mi

O sa gbese Igbala mi

Ni Kalfari.

Bayi, a ti bọwọ́ pẹlu ara wa. Ẹ jẹ ki a di oju wa, ki a si kọrin ninu Ẹmi, ka gbe ọwọ wa soke si I.

Mo fẹran. Jesu yii

Tori O kọ fẹ mi

O san gbese igbala mi

Ni Kalfari

Ah, Ṣe Oun kii ṣe iyanu bi?

Iyanu, Iyanu, ni Jesu si mi

Olutunu mi ni

Olodumare

O gba mi, pa mi mọ

Kuro ni n'ẹṣẹ

Iyanu L'Olugbala, Yin Ookọ Rẹ!

Iyanu, Iyanu ni Jesu si mi

Olutunu mi ni

Olodumare

O gba mi, Pa mi mọ

Kuro ni n'ẹṣẹ

Iyanu l'Olugbala Yin Ookọ Rẹ!

99 Ah, se inu rẹ dun nipa iriri rẹ pẹlu Kristi? Oun ko ha jẹ Iyanu bi? Ko ha tẹnilọrun bi?

Mo sọnu, O gba mi

Ko si dalẹbi mọ

Jesu tu mi silẹ

Mo nigbala kikun

O gba mi, pamimọ

Kuro ni n'ẹṣẹ

Iyanu l'Olugbala, Yin Ookọ Rẹ!

Ah, Iyanu, Iyanu, ni Jesu si mi.

Olutunu mi ni

Olodumare

O gba mi, pami mọ

Kuro ni n'ẹṣẹ

Iyanu l'Olugbala Yin Ookọ Rẹ!

100 Ṣe Iwọ gbagbọ pe iyẹn ba Ọrọ Ọlọrun mu? Bibeli wipe, “patẹwọ, ẹ ho iho ayọ si Oluwa.” Se o mọ, mo ti ma a nfẹ fi ohun elo kọrin. Ọmọbinrin mi Rebekah, ntẹ piano. Ọmọkunrin mi kekere nlo kakaki. Ṣugbọn emi kọ ohun elo orin olokun mẹwa.

Iyanu, Iyanu, ni Jesu si mi,

Olutunu mi ni

Olodumare

O gba mi, pa mi mọ

Kuro ni n'ẹṣẹ

Iyanu l'Olugbala, Yin Ookọ Rẹ!

Ṣe iwọ fẹran Rẹ?

A rin n'u 'mọlẹ, Mọlẹ didan

Wa sibi ti iri anu ti nṣan

Tan yi wa ka lọsan ati loru

Jesu, Imọlẹ aye.

A nrin n'u 'mọlẹ, 'Mọlẹ didan

Wa sibi ti iri anu ti nṣan

Tan yi wa ka lọsan ati loru

Jesu, Imọlẹ aye.

101 (Fifi kíkùn kọrin) Yin Ọlọrun pẹlu ohun gbogbo ti o ni. (Kíkùn)

Gba tawọn, mimọ wọle.

Gba t'awọn mimọ nwọle

Oluwa, jọ ka mi mọ wọn

Gba t'awọn mimọ nwọle

Gbati a ba de l'ade.

De l'ade Ọba 'wọn ọba

Oluwa jọ ka mi mọ wọn

Gba ti a ba de l'ade

Gbati orun ko ni ran

Gbati orun ko ni ran

Oluwa jọ ka mi mọ wọn

Gbati orun ko ni ran.

Se o nifẹ iyẹn? Bayi, mo fẹ mọ bi a ba ti gba ẹṣẹ̀ rẹ la. Iwọ kii jo mọ lode lọhun fun aye. Jẹ ki a jo fun Oluwa, ati si Oluwa. Se ọwọ rẹ ti ni igbala? - Iwọ ko jale mọ? Ete rẹ ti ni iyipada - iwọ ko parọ mọ? Iwọ ma kan ni ẹsin ni ọpọlọ rẹ; ni in ni gbogbo ara rẹ, bẹẹ ni! O nilo gbogbo aye eniyan. Otitọ niyẹn Bayi jẹ ki a jo.

Gba t'awọn mimọ wọle

Gba t'awọn mimọ nwọle

Oluwa jọ ka mi mọ wọn

Gba t'awọn mimọ nwọle.

Gba t'awọn mimọ nwọle

Gbat'awọn mimọ nwọle

Oluwa, jọ ka mi mọ wọn

Gba t'awọn mimọ nwọle.

Bayi, jẹ ki a gbe ọwọ wa soke.

Gba t'awọn mimọ nwọle

Gba t'awọn mimọ nwọle

Oluwa jọ ka mi mọ wọn

Gba t'awọn mimọ nwọle

Gbati a ba de lade

De lade Ọba wọn Ọba

Oluwa jọ ka mi mọ wọn

Gbati a ba de lade

102 Ṣe iwọ ko fẹran Rẹ bi?

Nigba naa, A o rin nu 'mọlẹ (oun ni imọlẹ)

Imọlẹ didan

Wa sibi ti iri anu ti nṣan

Tan yi wa ka lọsan ati loru

Jesu Imọlẹ aye.

Ṣe iwọ gbagbọ pe Oun ni Imọle aye? Paulu wipe, “Emi yoo kọrin ninu Ẹmi. Bi mo ba jọsin, Emi yoo jọsin ninu Ẹmi.” Ohunkohun ti iwọ ba ṣe, ṣe gbogbo rẹ ninu Ẹmi. Ẹmi si nmu Ọrọ naa wa si Iye. Sẹ bẹẹ ni? Bẹẹ ni, Bẹẹ ni, sa.

Ẹyin mimọ, ẹ kede

Jesu Imọlẹ aye

Oore ọfẹ at'anu

Jesu imọlẹ aye (Nigba naa kin ni a o ṣe?)

Ao rin n'u mọlẹ, mọlẹ didan

Wa sibi ti iri anu ti nṣan

Tan yi wa ka lọsan ati loru

Jesu, Imọlẹ aye

103 Ẹ ma binu ẹyin to nlo ohun elo orin pe mo ya kuro, o si siyin lọna, sugbọn mo ti gbagbe ara mi. Emi ko mọ ju ki nsa ti jọsin lọ. Bi a ti nṣe e niyẹn. Bẹẹ ni sa. Mo dupẹ fun anfaani yii, Arakunrin Mack. Ti ẹ fun mi lati wa jọsin pẹlu iwọ ati ijọ rẹ lalẹ yii, pẹlu gbogbo awọn eniyan to dara yii. Ẹyin ti ẹ nawọ yin soke fun ibaptisimu Ẹmi Mimọ, mo fẹ ki ẹ ri Oluṣọ-aguntan Mack nibi, tabi ọkan ninu wọn, ki ẹ si lọ sinu iyara kan nibi yii. Si ranti pe, nigbati Ọlọrun sọ Ọrọ ni atetekọṣe wipe, “Jẹ ki ohun kan wa” O nilati wa. O si wipe, “Alabukun fun ni awọn ti ebi npa, ti oungbẹ ngbẹ si ipa ododo, nitoriti, wọn yoo yo.” O nilati ṣẹlẹ. Wa ba Oluṣọ-aguntan yin nibi yii, ki ẹ si duro tii, bi o ti nwaasu ihinrere.

104 Bayi, ẹ jẹ ki a kọrin atijọ yẹn, emi sa fẹran Iyẹn. A o rin ninu imọlẹ. Jesu wipe, “Emi ni Imọlẹ aye”, iwọ si wa ninu Rẹ. Bawo ni a ṣe nde inu Rẹ? Didara pọ mọ Ọn? Rara. Bibọ ọwọ? Rara. Itẹbọmi? Rara. Nipa Ẹmi kan ni a baptisi wa sinu ara kan, tii ṣe ara Kristi. Ninu ara naa si ni ẹbun mẹsan ti Ẹmi wa, ti wọn nsiṣẹ ninu ara Ijọ adugbo kan. Iyẹn jẹ ẹkọ awọn aposteli bi mo ṣe mọ ọn to. Otitọ niyẹn.

A o rin nu mọlẹ

Imọlẹ didan

Wa sibi ti iri anu ti nṣan

Tan yi wa ka lọsan ati loru

Jesu Imọlẹ aye.

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7

www.messagehub.info